# Jèhófà-Jírè Apá Kẹta

Louisville, Mississippi, USA

Ọjọ Kẹrin, Oṣu Kẹrin, 1964

1 Ẹ tẹriba iṣẹju kan fun gbadura.

O si pe orukọ ibẹ ni Jehofa-jire: bi a ṣe ri i lori oke OLUWA titi di oni.

Baba wa Ọrun, a dupẹ ni alẹ oni fun anfaani ti a ni yii lati pejọ pọ ni Orukọ Jesu Oluwa, lati sin-in ninu Ẹmi ajinde Rẹ. A dupẹ pupọ lọwọ Rẹ, fun ohun ti O ti ṣe fun wa, nipa fifi ara Rẹ han pẹlu wa nipa Ọrọ naa laarin wa, ati nipa ajinde. Ireti wa ga pupọ, Oluwa, nitori a mọ wipe - wipe Ọlọrun ti a n sin kii ṣe ọlọrun itan kan, ṣugbọn Ọlọrun lọwọlọwọ ni, Ẹniti o jinde kuro ninu oku, ti o si ti fihan wipe Oun ni Ọlọrun ti o wa pẹlu Mose, ati pẹlu Abrahamu, ati gbogbo awọn aposteli, O si jẹ Ọlọrun kannaa sibẹ. Njẹ awa… A darapọ mọ Eddiẹ Perronet, bi o ti wipe, "Igbagbọ mi duro lori ẹjẹ at'ododo Jesu." Nitorinaa, a dupẹ lọwọ Rẹ fun itura ati itunu nla ti a ni yii.

Baba, ni aṣalẹ yii, bi ẹnikan ba wa laarin wa ni aṣalẹ yii, ti ko ni ireti nla yii, jẹ ki eyi jẹ wakati naa ti a o fi Otitọ Ainipẹkun kanṣoṣo naa han fun wọn, Baba, ki wọn lee mọ wipe idi ti wọn fi wa lori ilẹ aye kii ṣe lati - lati ṣiṣẹ nikan. Ọkan ninu awọn idi naa niyẹn nitootọ. Ṣugbọn idi pataki ni lati di ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun. Jẹ ki iyẹn pari ni aṣalẹ yii. Gba bẹẹ, Oluwa.

Bukun fun wa bayi, bi a ti n ni idapọ ninu Ọrọ Rẹ. Otitọ ni Ọrọ Rẹ. Jẹ ki Ẹmi Mimọ nla nni mu Ọrọ Ọlọrun, ki O si pin-in fun wa bi a ti nilo Rẹ, nitoriti a beere ni orukọ Jesu. Amin.

Ẹ lee joko.

2 Ẹ ṣeun fun anfaani lati tun pada ni aṣalẹ yii, ati lati wa niwaju ẹyin eniyan daradara yii lẹẹkan si i pẹlu Ihinrere ologo yii. A ti ṣe ikede wipe ni ile-ẹkọ Ọjọ Isimi owurọ ọla, awọn oluṣọ-aguntan ti wọn fọwọsowọpọ yoo ni ajumọṣe ile-ẹkọ Ọjọ Isimi nibi yii. Mo ro wipe iyẹn dara pupọ. Ọpọlọpọ wọn ni o ti gbe ijoko kuro ninu ijọ wọn, ti wọn si ko wọn wa sihin yii fun awọn eniyan, iṣe ti o dara pupọ niyẹn fun awọn eniyan lati ṣe.

A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun oju-ọjọ rere ti O fi fun wa. Wọn sọtẹlẹ wipe a o ni iji ati awọn nkan bẹẹ, ni gbogbo igba. Ṣugbọn O da iji naa duro, a ko si ni iṣoro kankan. A dupẹ fun iyẹn.

Ni bayi, a fi aṣalẹ yii fun… A ti n ṣe awọn ipade ihinrere bii ti tẹlẹ. Bi iṣoro kan ba wa pẹlu wa… A ko sọrọ pupọ lori - lori wipe ki ẹlẹṣẹ wa sọdọ Kristi. Mo mu akori kan ni alẹ Thursday ti o kọja, n koi si tii waasu lori rẹ sibẹ. A n sọrọ nipa Abrahamu, a ko si tii de ibi akori naa, akori Jehofa-jire. Nitorinaa, a n gbiyanju lati pari iyẹn ni aṣalẹ yii. A gbagbọ wipe Oluwa yoo gba gbogbo awọn ti koi tii ri igbala la, yoo si fi Ẹmi Mimọ kun gbogbo awọn ti koi tii kun fun-un ni aṣalẹ yii.

Ẹ ronu gidigidi lori rẹ bi a ṣe wa nibi yii. Nigbati a - nigbati a ba n sọrọ, ṣí ọkan rẹ paya ki Ẹmi Mimọ lee ba ọ sọrọ ninu rẹ. Kini a tilẹ n ṣe nibi yii gan-an? Ṣe ẹ ri i? Ronu lori iyẹn. Kini aye rẹ jẹ? Kini o wa nibi fun? Ṣe Ọlọrun… Ṣe o wa ni ipo ti Ọlọrun fi lee ri gbogbo - gbogbo idi ti O fi fi ọ sihin gba? Jade lati inu rẹ? Aijẹbẹẹ, ẹ jẹ ki a yanju rẹ ni aṣalẹ yii, ẹyin ọrẹ. O jẹ…

Mo - mo ni awọn ọrẹ kan ti wọn wa nibi yii, lati inu ijọ mi. Awọn kan… Ọkan ninu awọn alabojuto, ti mo mọ, ati arakunrin bii meji tabi mẹta. Mo ṣẹṣẹ ri ẹbi titun kan ti o joko sibi yii ni, ni aṣalẹ yii, ẹbi Palmer lati ibikan nibi yii, ti wọn n wa ọkọ fun ọgọọgọrun maili - ni gbogbo ọjọ Sunday ti mo ba n sọrọ ni Indiana. Ọgbẹni Welsh Evans ati ẹbi rẹ wa nibikan nibi yii. Emi ko mọ ibi ti wọn wa. Mo… Mo ti n ṣe aṣaro loni, ni gbogbo ọjọ, mo si gbọ ohun wọn ni ita nibẹyẹn. Mo si - mo mọ wipe wọn wa nibi.

3 Ni agogo meji ọla. [Ẹnikan sọ pe, "Agogo meji."] Ni agogo meji ọla, gbogbo isin ọsan ọla ni a ya sọtọ fun awọn alaisan, lati gbadura fun awọn alaisan. Ọpọ awọn eniyan ni o n pe e ni isin iwosan. O dara, awa ko fẹ lati maa pe e bẹẹ. Ẹ jẹ ki a pe e ni isin igbagbọ. Nitori bi igbagbọ wa ba lee dagba de ipo yẹn, lẹyin ti Oun ti fi ara Rẹ han laarin wa, ti O si mọ ohun gbogbo ti n bẹ ni ọkan wa, ti O si ti fidi rẹ mulẹ fun wa wipe Oun wa laaye, ti O si fidi rẹ mulẹ nipa Iwe Mimọ.

Njẹ ẹ kiyesi bi o ṣe ti gbogbo Ọrọ naa lẹyin, nipa Ifarahan iwalaaye Rẹ? [Ijọ sọ pe, "Amin."] Ṣe ẹ ri i? Ṣe ẹ ri i? Ṣe ẹ ri i? Ni bayi, iyẹn fihan wipe o ko nilati ronu wipe a kan n gbiyanju lati sọ nkankan ti o jẹ àlọ́ lasan. Ohun ti Bibeli yii ṣe ileri, Otitọ ni. Ṣe ẹ ri i? Otitọ ni gbogbo Ọrọ naa.

Ni bayi, mo lee má ni igbagbọ ti o to lati mu ki gbogbo Ọrọ Rẹ ṣiṣẹ, ṣugbọn emi ki yoo di ẹniti o ni igbagbọ yẹn lọwọ. Ẹnoku ni igbagbọ ti o to lọjọ kan, lati ba Ọlọrun rin ni ọsan ọjọ kan, o n rin lọ, o si lọ si Ile lai ku. Mo ro wipe ijọ nilati de ipo yẹn, sibi igbagbọ Igbasoke. Mo lee mai tii ni igbagbọ yẹn bayi, ṣugbọn n ki yoo di ẹniti o ni igbagbọ yẹn lọna.

Nitorinaa, a gba Ọlọrun gbọ wipe yoo fun wa ni igbagbọ nla tobẹẹ ni alẹ ọla, ti ki yoo si alailera kankan

ninu ile yii mọ, nigbati wọn ba wa fun adura. A o gba iyẹn gbọ. Ti a ba lee gba a gbọ bayi! Ni bayi, mo ti ri iyẹn ni ọpọlọpọ igba!

4 Mo ti ri awọn igba ti o jẹ wipe ẹgbẹrun mẹẹdọgbọn, ẹ ronu nipa rẹ bayi, kii ṣe ẹgbẹrun meji ati ẹẹdẹgbẹta o, ani ẹgbẹrun mẹẹdọgbọn iwosan ti o tayọ, eyiti o ṣẹlẹ pẹlu adura ẹyọkanṣoṣo: ni Durban, South Africa. N ko mọ iye ọkọ ti wọn ko kun… Meji ninu wọn yoo kun gbogbo ile yii, ti ẹ ba ko awọn ohun ti wọn ko si inu rẹ, awọn ọkọ Britain nla, pẹlu taya mẹfa tabi mẹjọ, awọn ọkọ naa tẹle ara wọn, wọn n bọ pẹlu awọn ọpa ati kẹkẹ arọ, tabi ohun ti wọn n pe ni kẹkẹ arọ, ohun kekere kan ti wọn fi n gbe awọn alaisan. Wọn n gbe wọn wa lati inu igbo. Ti kiniun ba yọ si wọn, wọn yoo gbe wọn gun ori igi. Wọn si n ṣe bẹẹ wa si ipade. Lati ri i wipe kiki… ọmọdekunrin kan lori pẹpẹ.

Ẹniti o kọkọ wa sibi pẹpẹ jẹ - obinrin kan. Wọn ṣe ami ọmọ-ẹyin Mohammed si ara rẹ, pẹlu ọda pupa kan ni aarin oju rẹ mejeeji. Mo beere lọwọ rẹ boya o lee sọ ede oyinbo. O sọ pe, “Diẹ.”

Mo si wipe, “Mo ri i wipe ọmọ-ẹyin Mohammed ni ọ.”

O ni, “Bẹẹni.”

Mo ni, “Kini idi ti o fi wa si ọdọ emi Kristẹni? Kini ṣe ti o ko lọ si ọdọ awọn alufaa rẹ?”

O ni, “Mo gbagbọ wipe o lee ran mi lọwọ ni.”

Mo si tun ni, “O dara, emi ko lee ran ọ lọwọ, ayafi ti o ba gba Jesu Kristi gbọ.”

O sọ pe, “O dara, mo ti ri awọn ipade naa.”

Ọjọ kẹta ti a wa nibẹ ni o. Awọn eniyan ti o to ẹgbẹrun lọna igba ni o joko sibẹ ni akoko yẹn. Wọn ṣe ọgba yi i ka, nitori wọn n ja ogun ẹlẹya-mẹya ni akoko naa.

Mo si wipe, “O dara, o nilati gbagbọ ninu Jesu Kristi bayi.” Mo tun sọ pe, “Njẹ o ka Majẹmu Titun ri?”

O ni, “Mo ti ka a.”

Mo ni, “Kini o ro nipa iwaasu ti mo ṣẹṣẹ waasu tan yii, nipa wipe Oun jẹ ọkannaa lana, loni ati titi lae?”

O ni, “Mo gba a gbọ.”

Mo si wipe, “Njẹ ti Jesu Oluwa ba wa laaye loni, O ti wo ọ san na. Nipa ti ijiya Rẹ̀, iyẹn ti yanju. Ṣugbọn O nilati ni igbagbọ. Ti Ó ba wà nibi, yoo mọ ẹniti o jẹ. Yoo mọ ohun ti o ti ṣe. Yoo mọ ohun gbogbo nipa rẹ. Ṣe o gba iyẹn gbo?”

O ni, “Bẹẹni, sà.”

Mo ni, “Ti yoo ba fi iyẹn han, ṣe o gbagbọ nigbanaa wipe Oun ni Ọmọ Ọlọrun, ati wipe O jinde kuro ninu oku, O si wa laaye bayi? Ẹmi Rẹ̀ wa ninu mi, ati pẹlu awọn Kristẹni ti o ku wọnyi?”

O ni, “Mo gba a gbọ.”

Mo ni, “Ohun ti o wa nibi fun… Ọkọ rẹ jẹ eniyan kukuru, o si sanra. O ni irun-imu dudu. Ni ọsẹ meji ṣẹyin, o lọ sọdọ dokita kan. Orukọ rẹ niyi.” Emi ko lee kọ ọ, n ko lee pe e. Mo nilati pe e ni ọkọọkan ni. Orukọ Musulumi ni.“

O ni, “Otitọ niyẹn.”

Mo si wipe, “Ọkọ rẹ wa ninu gbọngan yii. O wọ aṣọ otutu alawọ eeru ati fila alawọ rẹsurẹsu.” Mo ni, “Dokita rẹ jẹ ẹni giga, ko sanra, o n lo awo-oju nla kan. O ṣe ayẹwo obinrin fun ọ, o si ri i wipe nkankan ti wu si ile-ọmọ rẹ.”

O ni, “Otitọ niyẹn.”

Mo ni, “Ṣe o gba Jesu gẹgẹbi Olugbala rẹ?”

O ni, “Ki Jesu Kristi jẹ Olugbala mi.”

Ẹniti o nkan lẹyin rẹ ni ọmọkunrin kan ti oju rẹ dà.

5 Wọn jẹ ki awọn akiriwaasu lọ, lati mu ẹnikan tabi meji ninu awọn ẹya kọọkan. O ko lee da wọn duro, ko si ọna lati ṣe bẹẹ rara. Nitorinaa, wọn ni ọpọlọpọ awọn ọmọ ologun lati da wọn duro, wọn ko si lee ṣe e.

Ọmọdekunrin ti oju rẹ dà yi, wọn gbe e wa sori pẹpẹ, o jinna diẹ si mi.

Awọn òdòdó nla wa lori pẹpẹ. Ẹyin arabinrin ti ẹ fẹran ododo! Awọn kan ninu awọn ododo ibẹyẹn gun to inṣi mejidinlogun; pupa, funfun, wọn si rẹwa. Wọn ni iyẹn. Wọn n dalẹ hu funra wọn ni. Wọn ni awọn ododo ti o wa ni ayika.

Emi n sọrọ lọ. Wọn gbe ọmọdekunrin kan wa sibẹ. Akiriwaasu yẹn gbe e sibẹ. Oju ọmọ naa dà. O ṣẹṣẹ jẹ ounjẹ ọsan rẹ tan ni.

6 Nigbamiran - ounjẹ wọn pa ni lẹrin. O ni… Wọn yoo mu kalamu kan, wọn yoo si lu iho si ara maalu, sinu ohun kan ti wọn n pe ni - ladugbo. Apo kekere kan ni, awọ ti wọn ran papọ, wọn yoo si jẹ ki - ẹjẹ naa, ẹjẹ gbigbona ṣàn sinu rẹ̀. Wọn yoo fa wara diẹ sinu rẹ, wọn yoo po o papọ, wọn yoo si fi ṣe - ohun mimu ti o dun.

Iwọ ko fẹ iru nkan bẹyẹn, tabi bẹẹkọ, ọmọ? Rara.

Iyẹn ni ohun ti o n jẹ. Oju rẹ si dà. Mo ni, “Ẹnikẹni ti o ba lee riran, yoo mọ ohun ti o n ṣe ọmọde yii. Oju rẹ dà. Ti mo ba lee ran ọmọde naa lọwọ,” mo ni, “dajudaju, emi yoo ṣe bẹẹ. Ṣugbọn emi - emi ko lee ran-an lọwọ, gẹgẹbi ẹnikẹni ko ti lee ran-an lọwọ pẹlu.” Mo ni, “Ti dokita kan ba lee ṣe e, ti ko si ṣe e, a jẹ wipe nkankan ti kuro ninu ọkan dokita naa, ti o ba lee ṣe e.” Mo ni, “Emi ko ro wipe wọn ni ọna ti wọn lee gba ṣe e ni akoko yii.”

Mo ni, “Ṣugbọn ni bayi, Oluwa lee fi nkankan han mi nipa ọmọde naa. Lẹyinnaa, O wipe, 'Ọmọde yii, baba ati iya rẹ ko sanra.'” Iyẹn ni… Eya Zulu ni, wọn si maa n saabaa sanra. Mo ni, “Awọn ni o joko sibi yii. Bayi-bayi ni orukọ wọn.” Mo si tun wipe, “A bi ọmọ naa pẹlu oju dídà ni. Nitori iya rẹ… Ibi ti wọn ti wa… Kristẹni ni wọn, nitori ninu ile kekere ti wọn n gbe, ahere ti a fi ewe bo orule rẹ ni, aworan Kristi si wa nibẹ, wọn gbe e kọ apa ọtun ara ogiri.”

Mo tun wipe, “Ọmọde naa, kete ti iya rẹ fi ọmọ naa han baba rẹ, oju rẹ dà.” Baba ati iya rẹ dide duro, lati fihan wipe otitọ ni. Mo pada wo ọmọ naa, oju rẹ si tọ bii temi.

Nitorinaa, mo wipe, “Ṣe ẹ ri i bayi, Oluwa,” mo ni, “Emi koi tii de ẹsẹ bata mẹwa si ibiti ọmọ yẹn wa, a si ti wo ọmọ naa san.”

Mo kuro lọdọ rẹ. Mo si pe ẹlomiran ti o n kan.

7 Nigbati iyẹn ṣẹlẹ, mo gbọ ti ohun gbogbo daru papọ. Ọmọwe Bosworth ati Ọmọwe Ern Baxter, awọn alabojuto ipade mi, wọn n ba ẹnikan jiyan ọrọ kan lọwọ, emi si… wọn n pariwo. Ọkunrin yii n gbiyanju lati wa sori pẹpẹ, o fẹ goke wa sibẹ. Ọpọlọpọ awọn dokita ni o wa nibẹ, awọn dokita oniṣegun oyinbo wa nibẹ. Dokita oniṣegun oyinbo yii - o ni, o n sọrọ. O ni, “Mo fẹ ba a sọrọ nipa ọmọde yẹn.”

Mo boju wo ẹyin, mo ni, “Ki lo ṣẹlẹ, dokita?”

O ni, “Bawo ni o ṣe mọ wipe dokita ni mi?”

Mo ni, “Dokita ni ọ. O jẹ… England ni a ti tọ ọ dagba. Dokita Britain ni ọ.” Mo sọ ibiti o ti ka iwe fun-un.

O ni, “Ni bayi, Ọgbẹni Branham, mo mọ wipe ọgbọn ọpọlọ lee - lee ka ohun ti o wa ninu ọkan mi.”

Mo ni, “Emi ko ka ohun ti o wa lọkan rẹ, dokita.”

O si wipe, “Ṣugbọn ohun ti ko ye mi ni…” O ni, “Mo gbagbọ wipe Ọlọrun wa. Mo si mọ wipe òdòdó lili yẹn ko lee yè laisi Ọlọrun,” o ni, “nitoriti o ni iye ninu.” O ni, “Ṣugbọn ṣe O ṣe e fi ọwọ kan? Emi ni mo gbe ọmọde yẹn wa sori pẹpẹ. Mo ti yẹ ẹ wo. Oju rẹ dà nitootọ. Ọmọde naa niyi bayi, ti oju rẹ ti tọ. Kini o ṣe e, Ọgbẹni Branham?”

Mo ni, “Jesu Kristi ni.”

O wipe, “Wo o bayi,” o ni, “mo gbagbọ ninu Ọlọrun.” O ni, “Ṣugbọn mo fẹ beere ibẹere kan lọwọ rẹ, gẹgẹbi iranṣẹ Ọlọrun. Ṣe o fi oogun dudu mu ọmọde yẹn ni?”

Mo ni, “Ọgbẹni, ṣe ohun ti o n sọ ni wipe - ṣe Ẹgbẹ Awọn Oniṣegun Oyinbo ni Britain si fun ọ ni iwe-aṣẹ lati maa ṣe iṣẹ oniṣegun, o ko si mọ nipa oogun ju bẹyẹn lọ? Ti oogun dudu yoo ba mu oju ọmọ naa tọ, iṣẹ iṣegun ibilẹ ni o yẹ ki o maa ṣe.” Ṣe ẹ ri i?

O wipe, “O dara, sọ ohun ti o ṣe e fun mi?”

Mo ni, “Jesu Kristi ni.”

O ni, “Wo o,” o ni, “mo gbagbọ. Mo ni Ọlọrun wa ninu ododo lili yẹn.”

8 Ọgbẹni Bosworth si wipe, “Iwọ yoo bẹrẹ idaru-dapọ nibi yii o.” Nitoripe wọn ni iyapa nibẹ pẹlu, ṣe ẹ mọ.

Nitorinaa, mo wipe, “Iwọ yoo…” Ogun ẹyamẹya wa nibẹ, mo ni, “Iwọ yoo da ija igboro silẹ bayi o. Ma ṣe bẹẹ.” O ni, “O ti n lo akoko pupọ ju fun ọmọde naa.”

Mo si ni, “Ohun ti o nilati ṣe niyi. Ọmọde naa naro si ibẹyẹn. Iwọ ni o mu u wa sori pẹpẹ. Igbagbọ ọmọde naa, ati igbagbọ iya rẹ, nipa sisọ iyẹn fun-un, ni o wo ọmọ naa san. Oju rẹ dà tẹlẹ, emi kọ ni o fi ọwọ kan, ko tilẹ sunmọ ibi ti mo wa, tabi ohunkohun. Ni kete ti mo ri ọmọ naa, ti mo si pada wo ijọ, ni mo ri iran naa, ti o sọ ohun ti o jẹ, mo wo ẹyin, mo si ri oju ọmọ naa wipe o tọ́.”

O si goke wa si ibiti awọn gbohungbohun pupọ wa. O ni, “Mo gba Jesu Kristi gẹgẹbi Olugbala mi.” Ṣe ẹ ri i?

Nigbati mo fẹ kuro ni Durban, o fo ọgba, nibiti ọpọlọpọ awọn eniyan bii ẹgbẹrun mẹwa tabi ogun wa, o wipe, “O dabọ.” Mo kuro… ni Durban. Ẹ jọwọ o. Johannesburg ni. O fo jade sita, o di ẹgbẹ mi mu, o sọ fun mi wipe oun ti fi iṣẹ oun silẹ ni ilu naa, wipe oun yoo lọ si papa iwaasu, gẹgẹbi dokita ti o n waasu si awọn eniyan. Bi o ṣe n ba mi sọrọ lọwọ, o bẹrẹ si sọrọ ni ede miiran, bi o ṣe n ba mi sọrọ lọwọ. Otitọ niyẹn, oniṣegun oyinbo ni, ọmọ ijọ Anglican si ni.

9 Ẹniti o nkan nibẹ ni ọmọdekunrin kan, tabi ọdọmọkunrin kan. O… Emi ki yoo ni akoko lati ṣalaye nipa rẹ. O jẹ… O jẹ, o - o nilati maa fi ọwọ mejeeji ati ẹsẹ mejeeji rin. Wọn fi ẹwọn si ọrun rẹ, bii aja.

Mo ni, “Kai, ẹ wo ẹniti a n da loro. Bi ẹnikẹni ba lee ran-an lọwọ, ti ko si ṣe e, ẹni bẹẹ yoo jẹ ẹniti ko ni ọkan rara.” Mo ni, “Nitootọ, emi ko lee wo o san, ẹnikẹni mọ bẹẹ. Emi ko lee wo o san. Ohun ti Oluwa ba fihan mi wipe o ṣẹlẹ nikan ni mo lee sọ, tabi ohun ti o fa a, tabi nkankan. Nitori a ti ra iwosan na.

Mo fẹ ki ẹyin ti ẹ wa nibi, ti aisan n ṣe, mo fẹ ki ẹ mọ iyẹn. A ti ra iwosan na. A ti wo yin san na. Aini igbagbọ ni. Ohun gbogbo ni o ṣee ṣe fun awọn ti o ba gbagbọ. Ẹ ṣaa nilati gbagbọ bayi ni.

A ri i wipe ọmọde yii… ọmọde yii, mo - mo ni, “Ẹ mu u wa si oke nibi.”

Wọn si n fi ẹwọn fa a. O ronu pe, ni igbamiran, awọn ẹya naa maa n fẹ da awọn arinrinajo lara ya. Wọn yoo maa jo, ijo ibilẹ wọn, lati ri owo gba lọwọ awọn arinrinajo. O ro wipe mo fẹ ki oun jo ni. Ọpọlọ ọmọ naa ko tilẹ pe paapaa. Bẹẹni n ko lee sọ ọ laarin ọpọ ero bi eleyi, nitori wọn kii wọ aṣọ, ṣe ẹ mọ. Awọn obinrin wọn, awọn ọkunrin wọn, ati gbogbo wọn maa nwa ni ihooho. Nitorinaa, wọn - wọn kan… boya ibantẹ kan tabi nkankan. O da ọwọ mejeeji ati ẹsẹ mejeeji delẹ, o buru jai. Lẹyinnaa, mo… Wọn fi ẹwọn fa a bẹyẹn, wọn si mu u wa si oke; ẹwọn naa wa ni ọrun rẹ, oun ni wọn fi n dari rẹ. O n sọ pe, “A-ba-ba-ba.” Mo gbiyanju lati jẹ ki o mọ wipe kii ṣe ohun ti mo fẹ niyẹn. Mo…

“Si ogbufọ Zulu naa,” mo ni, “sọ awọn ọrọ wọnyẹn. Sọ fun-un wipe ki o farabalẹ, ki o si gbagbọ.”

O gboju soke, o wo mi. Mo ni, “Ni bayi, ọmọkunrin yii jẹ… O ti wa bẹẹ lati igba ti o ti wa ni kekere.” Mo ni, “Ohun ti o jẹ gan-an… Ohun ti o n ro bayi ni arakunrin rẹ. Yala, arakunrin rẹ n gun aja pupa kan, tabi ewurẹ kan. O si ṣubu.” Mo ni, “O di arọ. O n fi igi meji rin.” Mo tun ni, “Ni bayi, mo ri i wipe a mu ọdọmọkunrin naa lara da. O ti sọ awọn igi ti o fi n rin sigbo.”

10 Ni akoko yẹn, o to bii ogun iṣẹju ki wọn to dakẹ. Ọmọ naa joko sibẹ, ni nkan bii opopo mẹta si ibi ti a wa. O si wá, pẹlu awọn ọpa na lọwọ rẹ, o n sare gidigidi. A ti mu u lara da, nibiti o wà, nigbati ogbufọ Zulu yẹn n tumọ rẹ. Awọn ogbufọ mẹẹdogun ọtọọtọ ni o wa nibẹ. Ti o ba sọ ọrọ kan, o nilati duro titi ti gbogbo awọn ogbufọ naa yoo fi gbufọ rẹ tan. Ọmọ naa wa, o ko awọn ọpa naa le ori, bẹyẹn. A ti mu u lara da.

Lẹyinnaa, mo wo ayika. Mo si tun ṣe akiyesi, bi mo ṣe n wo o, mo ri i ti o dide duro. Iran naa niyẹn. Ko si ohun ti o lee da iyẹn duro. Rara. O ti pari ni igba naa, ṣe ẹ ri i; a kan n duro de ọrọ naa ni.

Ẹ wo o. Ni ọjọ Monday ti o n bọ yii, emi yoo pe ọmọ ọdun marundinlọgọta. Ọjọbi mi niyẹn. Mo si ti maa n ri awọn iran lati igba ti mo ti wa ni ọmọ kekere. Emi ko ri ọkan ninu wọn ki o kuna ri. Mo si fẹ beere lọwọ ẹnikẹni boya wọn ri ẹyọkan ti a sọ ti o kuna ri. Ko lee kuna. Ọlọrun ni.

Nitorinaa, mo ri i. Mo wa ronu pe, “Anfaani niyi fun mi lati mu ki awọn… lati pe ipe sibi pẹpẹ. Mo ri i ti o dide duro. Mo mọ wipe a o mu u lara da nigbanaa, nitori a ti fihan. O nilati ri bẹẹ. Ohun ti iran naa sọ niyẹn. Bẹẹ si ni o ri.

11 Ẹni melo ni o mọ wipe otitọ ni awọn nkan wọnyẹn? Eyi wa fun awọn alejo lati ri. [Ijọ sọ pe “Amin.”] Otitọ ni. Ko kuna ri. Ọlọrun maa n jẹ ki o ṣẹ nigbagbogbo.

Mo ronu pe, “Akoko niyi fun mi lati pe ipe wa sibi pẹpẹ.” Mo ni, “Ọmọdekunrin yii, emi ko lee wo ọ san. Ṣugbọn ti agbara Ọlọrun ba ti fi iran kan han mi, a jẹ wipe a o wo ọ san bayi. Ti a ko ba wo ọ san, a jẹ wipe wolii eke ni mi. Ṣugbọn ti a ba wo ọ san, ẹni melo ninu ẹyin ti ẹ wa nibẹyẹn ni yoo gba Kristi gẹgẹbi Olugbala yin?” Awọn Musulumi bii ẹgbẹrun mẹwa ni o wa nibẹ.

Ni ọjọ melo kan ṣaaju iyẹn, mo ti ba ọjọgbọn kan sọrọ. O ni, “Ohun ibukun nla niyẹn!” Ṣe ẹ mọ, lati inu iran Media ati Persia ni wọn ti wa. Wọn kii yipada. O ko lee yi ọkan ninu awọn eniyan wọnyẹn pada.

Wọn wa nibẹ, wọn joko sibẹ. Ọkan ninu awọn obinrin Musulumi naa ṣẹṣẹ gba Kristi ni, iyẹn si ni ipa lori wọn. Ọmọkunrin Mahatma Gandhi wa nibẹ.

Ọmọdekunrin yii wa nibẹ. Mo sọ pe, “Dide duro lori ẹsẹ rẹ. Jesu Kristi mu ọ lara da.” O si n gbiyanju lati maa ṣe “Ug-ug-ug,” bẹyẹn. Mo lọ sibẹ, mo mu ẹwọn naa ni ọwọ mi. Mo ni, “Dide duro. Jesu Kristi mu ọ lara da.”

Bibeli niyi. Ti gbogbo yin baa lee mọ ohun ti o ṣẹlẹ ni alẹ ọjọ melo kan sẹyin bayi, emi ki yoo gbiyanju lati sọ ohunkohun ti o lodi ninu eyi.

Ọmọ ti a n pọn loju yẹn, o rin, ẹyin rẹ si lọ ṣẹyin, bii ẹṣin. Ọwọ ati ẹsẹ rẹ; ọwọ rẹ ti dapaadi bii ẹsẹ rẹ, lọwọ irin. Fun igba akọkọ lọjọ aye rẹ, o dide duro lori ẹsẹ rẹ. Omije si n ṣan si ikun rẹ dudu, o sare lọ. Kii ṣe wipe a wo o san nikan, ọpọlọ rẹ pe pẹlu. Ṣe ẹ ri i?

Mo ni, “Si gbogbo ẹyin ti yoo gbagbọ bayi, ẹ jẹ ki wọn gbagbọ bi emi yoo ṣe gbadura. Mo fẹ mọ awọn melo nibi yii, ti yoo gba Kristi gẹgẹbi Olugbala?” Gbogbo rẹ dabi òkun. Akọsilẹ sọ pe ẹgbẹrun lọna ọgbọn awọn eniyan dudu, ti ko mọ ọtun yatọ si osi, ni o tọ Kristi wa.

12 Mo ranti wipe mo n sọrọ ni Kiwanis, laipẹ yii. Mo si ranti ẹniti o yan mi gẹgẹbi oniwaasu ni ijọ Missionary Baptist Church, ti o maa n ṣe yẹyẹ. Mo ni, “Ohun ti Bap-… Ohun ti ẹ n pe ni gbawere-mẹsin, ni o jere ọkan fun Kristi ni wakati kan, ju ẹgbẹrun mẹwa dọla ti ijọ Onitẹbọmi fi sinu eto ikiriwaasu nibẹyẹn.

Kini a ri i wipe wọn jẹ? Nibẹ, wọn pe wọn ni Kristẹni, bi eleyi, wọn si n gbe oriṣa kiri ni ọwọ wọn. “Ti Amoyah…” Amoyah tumọ si “agbara airi,” bii afẹfẹ. “Ti o ba kuna, eyi ki yoo kuna.” Agbara rẹ niyẹn. Nibẹ ni mo ti ri ẹgbẹrun lọna ọgbọn awọn eniyan dudu ti wọn fi aye wọn fun Kristi.

Wọn n lọ sọdọ awọn ẹya ti o wa nibẹ, wọn n jere awọn ọrẹ wọn fun Kristi. Mo gba adura ẹyọkan fun gbogbo wọn. Ni nkan bii wakati mẹrin lẹyin iyẹn, Sidney Smith, alaga ilu Durban, Sidney Smith, alaga ilu Durban, South Africa, pe mi lori ẹrọ tẹlifoonu. O ṣẹlẹ wipe obinrin kan ti ku ni alẹ kan ṣaaju ọjọ yẹn, wọn si pe mi lati gbadura. Obinrin naa si wa sibi ipade naa, o wa laaye. Ẹni yẹn jẹ ibatan Sidney Smith, inu rẹ si dun gidigidi.

Lẹyin eyi, o wipe, “Lọ si oju ferese rẹ ki o si wo ohun ti o n bọ loju titi.” Awọn ọkọ nla-nla si n bọ, ti o kún. Awọn ẹya eniyan dudu ti wọn ti wa ninu ibusun alaisan ni owurọ ọjọ yẹn, wọn bẹrẹ si rin tọ awọn ọkọ naa lẹyin, pẹlu ọwọ wọn loke, wọn n sọkun, wọn si n kọrin ni ede abinibi wọn, wipe, “Ṣaa ti gbagbọ. Ohun gbogbo lo ṣee ṣe.” Ko si si ogun laarin wọn mọ, wọn to lẹsẹẹsẹ, wọn si n bọ. Awọn ọkọ naa n lọ siwaju, awọn ẹṣọ ọlọpa tẹle wọn, awọn ọmọlanke si nilati maa lọ kaakiri. Ṣaa Ti Gbagbọ.

13 Njẹ ti awọn eniyan alawọ dudu ti wọn ko mọ ọtun yatọ si osi ba lee gba iyẹn, awa nkọ? Ṣe o ye yin? Njẹ ẹ mọ idi? A koi tii ko ẹkọ kankan si ọpọlọ wọn ri ni. Ṣe o ye yin?

Awa ti ni gbogbo eniyan. Ọmọwe Lagbaja sọ pe, “Gbawere-mẹsin ni.” Eyi naa tun sọ pe, “Ọgbọn ori ni.” Eyi wipe, “Ko si nkankan nibẹ.” Eyi sọ pe, “Eṣu ni.” O ko mọ eyiti iwọ iba gbagbọ. Idi ti o fi le niyẹn. Ibi ti o le ju lati ṣe isin imularada ni orilẹ ede Amẹrika. Bẹẹ ni.

Ni ọ̀hún yẹn, wọn ko mọ ohunkohun. Wọn koi tii gbọ nkankan. Iwọ ṣaa sọ fun wọn. Bii ọmọde ni wọn. Wọn yoo gba a, wọn yoo si gba a gbọ, wọn n lọ niyẹn.

Ki Oluwa ran wa lọwọ. A tun fẹ gbadura lẹẹkan si i. A ko lee gbadura ju, ohun kan ti o daju niyẹn. Bibeli wipe, “Emi iba fẹ ki awọn ọkunrin maa gbadura nibigbogbo, ki wọn maa gbe ọwọ mimọ soke.”

Gba wa, Oluwa, sinu idapọ Rẹ nibi yii, bi a ṣe n fi ara wa le Ọ lọwọ - idapọ Ọrọ Rẹ, nitori Iwọ ni Ọrọ naa. A beere ni orukọ Jesu, ba awọn ọkan sọrọ. Amin.

14 A… fi Abrahamu silẹ ni alẹ ana, a si … a bẹrẹ pẹlu rẹ … ni ori kejilelogun iwe Gẹnẹsisi, nibiti o ti n fi ọmọ

rẹ kanṣoṣo rubọ - apẹẹrẹ wipe Ọlọrun yoo fi Ọmọ Rẹ fun ni. A bẹrẹ lati ibẹ, a tun pada lọ mu u (igbe-aye rẹ), a ko si tii kuro nibẹ. A fi i silẹ ni alẹ ana ni ori kẹrindinlogun tabi ikẹtadinlogun. Mo gbagbọ wipe ori kẹẹdogun ni a ti fi i silẹ. A o gbiyanju lati pari rẹ ni aṣalẹ yii, nitori mo ni iwaasu kan fun iwosan atọrunwa, bi Oluwa ba fẹ, fun ọsan ọla. Gbogbo olusọ-aguntan ni a pe. Ẹ ko awọn ọmọ ijọ yin wa, ki ẹ wa duro ti wọn fun adura.

15 A mọ wipe Jesu maa n ṣe awọn nkankan nigbamiran … O maa n ṣe awọn nkankan nigbamiran… O lee wipe, “Eeṣe ti O fi aaye gba awọn nkan wọnyi nigbanaa, Arakunrin Branham? Eeṣe ti O fi aaye gba awọn nkan wọnyi lati ṣẹlẹ?” Igbamiran, a maa n ṣe e lati dan igbagbọ rẹ wo, ni ọpọ igba. O maa n ṣe awọn nkan ajeji. Kini ṣe ti ko jade sita, ki O si wipe, “Mo jẹ́ eyi, mo jẹ́ iyẹn?” Ko ṣe bẹẹ lati ibẹrẹ. O n ṣe e lati dan igbagbọ rẹ wo ni.

Ẹ wo o, awọn alufaa ro wipe yoo sọkalẹ wa ba Kaiafa sọrọ, iyẹn olori alufaa. Ṣugbọn bawo ni a ṣe bi i? Ni ibujẹ ẹran, awọn eniyan Rẹ si kọ ọ patapata, ati awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ igba yẹn.

16 A ri i wipe Jesu n sọrọ ni igba kan, gẹgẹbi… Ẹ kiyesi ayọka kan ti mo fẹ sọ nibi yii. Ọpọ awọn ero ni o n tọ Jesu lẹyin, o si dabi ẹni wipe wọn ti pọju. Ẹ kiyesi ohun ti O sọ. “Bikoṣepe ẹ ba jẹ ẹran-ara Ọmọ eniyan, ki ẹ si mu ẹjẹ Rẹ, ẹ ko ni iye.”

Kini ẹ ro wipe oniṣegun oyinbo, tabi ẹnikẹni ti o jẹ ọlọgbọn yoo ro, nigbati wọn ba gbọ pe ẹnikan ti wọn pe ni ọmọ ale, ti o si dabi ọmọ-ita loju awọn eniyan igba yẹn, ti o dide duro, ti o si sọ iru ọrọ bẹyẹn? “Bikoṣepe ẹ ba jẹ ẹran-ara mi, ki ẹ si mu ẹjẹ mi…” Wọn yoo sọ pe, “Ajẹẹyan ni ọkunrin yẹn! Kai! Ki a mu ẹjẹ eniyan, ki a si jẹ ẹran-ara rẹ kẹ? Ẹyin ijọ, ẹ jinna si iru aṣiwere bẹyẹn!” Ko ṣalaye rẹ titi. Ko ṣalaye rẹ titi; ko nilo lati ṣalaye rẹ. Bẹẹ ni. O kan fẹ wo iru igbagbọ ti wọn ni ni, ṣe ẹ ri i.

17 Iwọ … ti o ba gbagbọ, o gbagbọ niyẹn; emi ko bikita ohun ti ẹnikẹni lee sọ. Ti mo ba gbadura fun ẹgbẹrun marun eniyan ni aṣalẹ yii, ti gbogbo awọn ẹgbẹrun marun naa si ku ni aṣalẹ yii, ni owurọ ọla, emi yoo maa gbadura fun awọn alaisan sibẹ, ṣe ẹ ri i. Ohun ti Ọlọrun sọ ni o ṣe pataki; kii ṣe ohun ti awọn eniyan ṣe, ṣe o ye yin. Ọlọrun sọ pe, Bikoṣepe ẹ ba jẹ ẹran-ara Ọmọ eniyan, ki ẹ si mu ẹjẹ Rẹ, ẹ ko ni iye ninu yin.“

Kai, awọn eniyan wọnyẹn - awọn ọlọgbọn eniyan yẹn - wọn sọ pe, “Ẹ jinna si ọkunrin yẹn! Were ni! Ara igbo ni! Ajẹẹyan ni - ki a jẹ ẹran-ara ọkunrin yẹn kẹ!” Ko ṣalaye rẹ rara.

18 O ni awọn aadọrin oniwaasu ti a yan pẹlu Rẹ. O ro wipe awọn ero wọnyẹn ti pọju, awọn ero naa si lọ kuro lọdọ Rẹ. O wa ku awọn oniwaasu ti a yan nibẹ, O si ran wọn jade, awọn aadọrin. O ni, “Kini ẹ o sọ, nigbati ẹ ba ri Ọmọ eniyan ti O n goke lọ si ọrun, lati ibi ti O ti wa?” Ko ṣalaye rẹ titi.

Awọn oniwaasu naa wipe, “Ọkunrin yii yoo goke lọ si ọrun, lati ibi ti O ti wa kẹ? Kini, a mọ Ọ. A mọ iya Rẹ. A ti lọ si ibujẹ ẹran nibiti a ti bi i. A ri ibi ti wọn ti bi i. A ti jọ pẹja papọ. A jọ wa ni bebe odo pẹlu Rẹ ni. O si wipe 'Ọmọ eniyan yoo goke lọ si ibi ti O ti wa' kẹ? Ṣebi Bẹthlẹhẹmu ni o ti wá! Ewo tun ni wipe O wa lati oke? Eyi ti pọ ju fun wa ojare.” Wọn si kuro lọdọ Rẹ.

Ko ṣalaye rẹ titi. Ko ṣe e … Ko nilo lati ṣalaye ohunkohun. Ọlọrun ko nilo lati ṣalaye ohunkohun. Oun ni Ọlọrun. O maa n ṣe e, nitori O ti ṣe ileri rẹ. Kii ṣalaye rẹ.

Lẹyinnaa … awọn mejila pere ni o ṣẹku. O yi oju pada, O si wo wọn. O ni, “Ẹyin mejila kọ ni mo yan, ọkan ninu yin ko ha si jẹ eṣu.” O ni, “Ẹyin pẹlu n fẹ lọ bi?”

Igba naa ni Peteru sọ awọn ọrọ nla wọnni: “Ọdọ tani awa yoo lọ, Oluwa, nitori o da wa loju wipe Iwọ ni o ni ọrọ iye lọwọ.” Wọn ti ri i ti a fihan gbangba. Ko si ohun ti alufaa lee sọ, ohun ti ẹnikẹni lee sọ, wọn mọ lojukannaa wipe Oun ni o ni ọrọ iye lọwọ. Wọn ni, “Iwọ ni o ni ọrọ iye lọwọ.”

19 Ni bayi, a kiyesi i wipe ko si ohun ti awọn tó kù lee ṣe - bi wọn ṣe lọ kuro - a ti yan awọn ọmọ-ẹyin yẹn tẹlẹ. A ti yan wọn tẹlẹ si iye ainipẹkun. Rara, wọn ko lee ṣalaye rẹ. Wọn ko lee ṣalaye rẹ gẹgẹbi awọn ti o ku naa ko ti lee ṣalaye rẹ, ṣugbọn nkankan wa ninu wọn. Ikọ̀ wọn ni ọrun - ero ti Ọlọrun ni nipa wọn ṣaaju ipilẹṣẹ aye - ti fi ara rẹ han nibi. A so wọn pọ mọ Ọlọrun, o si da wọn loju wipe ileri Ọlọrun ti o farahan niyẹn. Ko si ohun ti o lee yi wọn pada kuro ninu rẹ. Ojulowo Kristẹni ti o daju niyẹn.

20 Loni, awọn eniyan ri bi wọn ṣe ri ni igbati awọn ọmọ-ẹyin wa loju okun. Ni alẹ ọjọ kan, igbi lile bẹrẹ. Ko si ohunkohun … gbogbo ireti wipe a o gba wọn la ti dopin. Wọn si ri i ti O n rin bọ lori omi. Omi ti kun inu ọkọ wọn, aṣọ ikele ti faya, ọpa itukọ wọn ti kán pẹlu. Wọn di mọ ara wọn, wọn n kigbe. Wọn wo ita, wọn si ri i ti O n rin bọ lori omi, ẹru Rẹ si ba wọn - ireti wọn kanṣoṣo si niyẹn. Wọn n bẹru ohun kanṣoṣo ti o lee gba wọn la. Aworan bi ọjọ oni ṣe ri niyẹn! Wọn ro wipe o ba ni lẹru. Ṣe ẹ mọ, O ni… Wọn kigbe, nitoriti wọn bẹru wipe iwin kan ni: O dabi … bii iwin.

Bẹẹ ni o ri loni. Ṣugbọn ti o ba lee ṣe bi wọn ti ṣe… Nigbati wọn kigbe sita, wọn gbọ ti ohùn naa wá,

wipe, “Ẹ ma bẹru. Emi ni. Ẹ maṣe bẹru. Ẹ mu ọkan le.” Ti ẹ ba kiyesi Ọrọ ileri fun ọjọ oni, ẹ o gbọ ohùn kan yẹn naa ti o n ti ipasẹ Ọrọ naa sọrọ. “Emi ni. Mo ṣe ileri lati ṣe eyi ni ikẹyin ọjọ. Ẹ maṣe bẹru. Ẹ maṣe foya. Ẹ fi igbẹkẹle yin si inu Mi, emi Ọmọ Ọlọrun [ẹniti O jẹ niyẹn]. Ẹ gba a gbọ bayi.”

21 A fi Abrahamu silẹ niwaju Elohiimu ni alẹ ana, nibi ti a ti mu u wa nipasẹ awọn ileri naa. Ileri ti o kẹyin ki ọmọ ti o n bọ naa to de, a ri i wipe ọkunrin kan wá - o mura bii eniyan, o jẹun bii eniyan, o sọrọ bii eniyan - Abrahamu wo o, o si ba a sọrọ gẹgẹbi Ẹlohiimu. Ẹlohiimu. Awọn meji lọ si Sodomu lati waasu nibẹ, a si fi iyẹn we ọjọ oni. Gbogbo yin ni ẹ ranti itan naa, nibiti a ti danu duro. Bakannaa ni, gẹgẹbi Jesu ti sọtẹlẹ wipe yoo ri bi o ṣe ri ni igba Sodomu, ipo kannaa ni aye wa ni aṣalẹ yii. Njẹ ti…

22 Mo joko si ibẹyẹn loni, mo si n ronu, mo ronu nipa gbogbo nkan wọnyi. Ilẹ-riri miiran tun ṣẹlẹ nibẹyẹn, wọn si wipe … o mi ilu naa titi. Mo ronu pe, “Kini eleyi? Njẹ ẹ mọ, ọjọ Friday Rere ni o ṣẹlẹ. Ṣe ẹ mọ, ni ẹẹdẹgbaa ọdun ṣeyin, ni ọjọ Friday Rere, ijọ kọ Jesu Kristi, ilẹ-riri si mi gbogbo aye. Wọn si tun ti kọ ọ ni igba Laodikea, bi Bibeli ti sọ wipe wọn yoo ṣe - wọn ti le e jade sita.

Igbesẹ ẹsin agbaye yii, ni igbesẹ ti awọn Igbimọ Ijọ n gbe. Wọn n padanu ẹkọ ihinrere wọn ati awọn nkan miiran. Ẹni meji ha lee rin pọ laiṣe wipe wọn rẹ́? Ẹ ko lee ṣe e. Iyẹn ko lee ṣiṣẹ pẹlu Ojulowo Kristẹni tootọ. Wọn ki yoo gba a laelae. Rara, sà. Kristẹni ti a ti tun bi ki yoo wọ inu ikẹkun bi iyẹn. O dabi igba ti a fi pẹpẹyẹ sinu àgò. O ti mọ wipe ibi iku ni oun n lọ. O ko lee dari rẹ sinu iyẹn. Nitorinaa, Ojulowo Kristẹni ti a ti tun bi yoo takete si nkan yẹn.

23 Abrahamu duro sibẹ, o n ba Ọkunrin kan sọrọ, ti O kọ ẹyin Rẹ si agọ ibi ti Sarah wa. Abrahamu si … Orukọ Abrahamu ni ọjọ kan tabi meji ṣaaju igba yẹn n jẹ Abramu ati Sarai; ṣugbọn bayi, o ti di Sarah ati Abrahamu. O si ba Abrahamu sọrọ pẹlu orukọ rẹ gẹgẹbi baba, ati alufaa. “Abrahamu, nibo ni iyawo rẹ Sara [ọmọbinrin ọba], wà?”

O ni, “O wa ninu agọ lẹyin Rẹ.”

O ni, “Emi yoo bẹ yin wo ni ibamu pẹlu ileri naa, ani akoko iye [iyẹn ni wipe, ni oṣu kan si i]. Emi yoo bẹ yin wo gẹgẹbi mo ti ṣe ileri.” O ti n duro ọdun mẹẹdọgbọn fun ọmọ ileri yii, ko ṣiyemeji Ọrọ Ọlọrun nipa aigbagbọ, ṣugbọn o lagbara, o si n fi iyin fun Ọlọrun. Ẹ kiyesi eyi bayi.

24 Lẹyin eyi, Sarah, ninu agọ (ti a ba fẹ sọ ọ ni ede mẹkunnu), o dabi ẹni wipe o rẹrin sinu ara rẹ. O ni, “Emi, iya arugbo, ọmọ aadọrun ọdun, wipe n o ni ayọ pẹlu oluwa mi, ọkọ mi?” Oun ti o ti pe ọmọ ogọrun ọdun, a ko ṣe bii ọkọ ati aya mọ lati ọpọ ọdun sẹyin.

Ọkunrin naa kọ ẹyin Rẹ si agọ, O si wipe, “Eeṣe ti Sarah fi ṣiyemeji iyẹn, ti o si n sọ awọn nkan wọnyi ninu ọkan rẹ?” Iyẹn ni Abrahamu fi mọ ẹniti o n ba oun sọrọ. Ẹlohiimu niyẹn - bẹẹ gan-an ni. Ami Rẹ fi ẹniti O sọ wipe Oun jẹ han.

O ni, “Emi yoo bẹ yin wo.” Kini idi ti O fi sọ wipe “Emi”? Bawo ni o ṣe pe e ni Abrahamu - Oun ni o fun-un ni orukọ naa gẹgẹbi ami, kii ṣe niwaju eniyan - O n fi ohun ti yoo ṣẹlẹ han; O fi aṣẹ rẹ ti a fihan fun-un (ọrọ ti a ṣe ileri rẹ) wipe Ọkunrin ti O n ba oun sọrọ yii, Ọlọrun ni, Ẹlohiimu ni.

25 A ri i ninu iwe Heberu, ori kẹrin, ẹsẹ ikejila (bi mo ti ṣe ka a lẹẹmeji sẹyin ni alẹ ọjọ meji ti o kọja), wipe Bibeli sọ pe Ọrọ Ọlọrun n mọ ero ti o wa ninu ọkan, ani aṣiiri ọkan. Nigbati Jesu wo awọn ijọ naa, O mọ ero ọkan wọn, O sọ fun obinrin yẹn, iye ọkọ ti o ti ni, O sọ ibi ti Nataniẹli wà fun-un, iyẹn ni ami ifihan wipe Oun ni Messiah naa, Ọlọrun Immanuẹli, nitori Oun ni Ọrọ naa.

Bi awọn wolii ṣe ri niyẹn. A ka awọn wolii si ọlọrun. Ṣe o ye yin. Jesu funra Rẹ sọ bẹẹ. O ni, “Bawo ni ẹ ṣe lee da mi lẹbi, nigbati o jẹ wipe ẹ n pe awọn ti Ọrọ Ọlọrun tọ wa, ẹ n pe wọn ni ọlọrun. Bawo ni ẹ ṣe lee da mi lẹbi nigbati mo sọ pe Ọmọ Ọlọrun ni emi iṣe? Bi Emi ko ba ṣe iṣẹ Baba Mi, ẹ maṣe gba a gbọ.”

26 Oun ni Ọrọ Ọlọrun ti a fihan fun iran yẹn.

Iba ṣe wipe O ba wá pẹlu ami Mose ni, ki yoo ṣiṣe. Ti Mose ba wa pẹlu ami Noah, a ko sọ ọ tẹlẹ fun ọjọ yẹn. Gbogbo awọn alufaa wọnyi, ati ẹkọ ẹsin, ati ile-iwe giga, ati awọn ile-iwe, ati awọn ọmọwe oniwaasu - iyẹn dara. A ko ni ohunkohun lodi si iyẹn. Ṣugbọn iyẹn kọ ni iṣẹ-iranṣẹ iwaasu akoko yii. Iyẹn wa fun ọjọ ikuuku yẹn. Imọlẹ yoo wa ni akoko aṣalẹ. O ṣe ileri awọn nkan wọnyi. Mo ti ka wọn lera-lera lati inu Ọrọ naa. O sọ pe, “Bi o ṣe ri ni igba naa, bẹẹ ni yoo tun ri.” Mo lee so o pọ mọ gbogbo ẹsẹ Iwe Mimọ ninu Bibeli, ki n si fihan yin wipe otitọ ni.

27 A fi ohun ti O sọ wipe Oun jẹ han nigbati O sọ ẹniti Sarah jẹ … ohun ti o ṣe lẹyin Rẹ. Ẹ kiyesi i bayi, O ṣe ileri wipe ni oṣu ti o n bọ, yoo loyun. “Gẹgẹbi akoko iye,” ni O sọ.

Ẹ kiyesi i bayi, ipa ọna Abrahamu jẹ apẹẹrẹ iru-ọmọ alade nisisiyi. Njẹ ẹ kiyesi i, Abrahamu … ileri naa

wa fun oun ati fun awọn ọmọ rẹ lẹyin rẹ. Awọn ọmọ rẹ si jẹ, lakọkọ, awọn iru-ọmọ ti ara; lẹyinnaa, iru-ọmọ alade, eyiti iṣe Kristi. Iru-ọmọ akọkọ, eyiti o wa nipa ibalopọ, ibẹ ni Isaaki ti jade wa; ṣugbọn lai si ibalopọ ni Jesu gba wa, iru-ọmọ alade naa.

28 Wipe ẹjẹ naa… Ẹjẹ ni a fi gba wa la; laisi itajẹsilẹ, imukuro ẹṣẹ ko si. Ẹ kiyesi i, Jesu ki iṣe Juu, Jesu ki iṣe Keferi, Ọlọrun ni Jesu. Ki iṣe… Ko lee jẹ Juu tabi Keferi. Ẹ wo o, iru ọkunrin ni o n mu ẹjẹ wa, eyiti iṣe iye ẹjẹ. Inu iye ẹjẹ ni iru-ọmọ wa.

Ẹyin ti ẹ wa nibi yii, ọpọlọpọ yin… Mo n gun ọkọ lọ kaakiri ni ijelo, mo n wo awọn agbẹ yin, ẹ ni adiyẹ. Agbebọ adiyẹ lee ye ẹyin kan. Agbebọ adiyẹ kan lee ye ẹyin; ṣugbọn ti ko ba ba akọ pade tẹlẹ, ko lee di ọmọ. O lee ye ẹyin, nitori inu abo ni ẹyin wa. Ṣugbọn ẹjẹ … inu ẹjẹ ni iye wa.

29 Nitorinaa, iye rẹ jẹ iye ti a da, ki iṣe nipa iru eniyan.

Pẹlupẹlu, ẹyin naa ki iṣe ti Maria, nitori iba ṣe wipe ẹyin naa jẹ ti Maria ni (gẹgẹbi ọpọlọpọ awọn ijọ Alatako Katoliiki ṣe gbagbọ, ati awọn ijọ Katoliiki funran wọn pẹlu - wipe ẹyin naa jẹ ti Maria), njẹ iyẹn … wipe ẹyin Maria ni, iyẹn yoo sọ ọ di eniyan lasan. Rara. Ti ẹjẹ naa ba jẹ Ọlọrun, bẹẹ ni ẹyin naa jẹ Ọlọrun. Nitori Maria ko lee mu ẹyin yẹn wa … ṣe ẹ mọ, ṣe ohun ti mo n sọ ye yin. Ko lee ṣe iyẹn laisi imọlara. Nitorinaa, ti ẹ ba sọ wipe imọlara wa nibẹ, kini ẹ n sọ wipe Ọlọrun ṣe nigbanaa? Yoo tun jẹ ibalopọ lẹẹkan si i, ṣe ẹ ri i. Nitorinaa, ati ẹyin, ati iye ẹjẹ naa, Ọlọrun ni. Amin.

Iyẹn ni… Gba iyẹn gbọ, iwọ yoo si ni igbagbọ lati tẹsiwaju. Ki iṣe ẹjẹ Juu ni a fi gba wa la, tabi ẹjẹ Keferi. Ẹjẹ Ọlọrun funra Rẹ ni a fi gba wa la, iye ẹjẹ ti a dá.

30 Gẹgẹbi mo ṣe sọ… Ẹ wo agbebọ adiyẹ. Akoko ojo n bọ bayi. Mo n ṣe akiyesi ni ijelo, bi wọn ṣe n ko koriko gbigbẹ, ti wọn si lọ n fi ṣe itẹ wọn. O lee lọ ṣe itẹ si ibẹyẹn, ki o si ye ẹyin kun inu rẹ; ki o joko sori rẹ, ki o saba le wọn lori, ki o si jẹ olootọ si awọn ẹyin naa, tobẹẹ ti yoo rẹ ẹ de ibi wipe, ko ni lee fo kuro ninu itẹ naa lati wa nkankan jẹ. Ṣugbọn ti akọ ko ba gun-un tẹlẹ, awọn ẹyin naa ko lee di ọmọ. Wọn ko ni iye ninu. Ẹ mọ bẹẹ. Wọn yoo wa ninu itẹ naa, wọn yoo si di òbu.

31 Bi o ṣe ri pẹlu awọn ijọ wa kan niyẹn. A ni itẹ ti o kun fun òbu ẹyin. Wọn ko ni igbagbọ Abrahamu. Akoko ti to lati fọ itẹ naa mọ, ki a si bẹrẹ ni ọtun. Ni ibaṣepọ, ki iṣe pẹlu ijọ ẹlẹkọ-adamọ kan, tabi ile-ẹkọ ẹsin kan; ṣugbọn ni ibaṣepọ pẹlu akọ naa, iyẹn Kristi Jesu, ẹniti yoo mu ki Ẹmi iye ti o wa ninu rẹ lee bi ọmọ. Oun ni O lee mu ki o gba a gbọ.

Ẹ fọ itẹ naa mọ, ki ẹ tun bẹrẹ ni ọtun. Ẹ n fi ọwọ ra wọn ni ẹyin, ẹ si n gba wọn wọle, ẹ n sọ wọn di diakoni - awọn ti wọn ti ni iyawo ni igba mẹrin tabi igba marun-un, ati ohun gbogbo bẹẹ. Ibo ni a tilẹ fẹ ba aye yii ja gan-an? Ẹ n ran wọn lọ si ile-ẹkọ ẹsin, ẹ si n fi ororo ikunra oku si inu wọn, ẹ o ko wọn pada wa, ẹ o si…

Nibi ni ijelo, ki a tilẹ bu u bẹẹ, o fihan wipe ida mọkandinlọgọrun ninu ida ọgọrun awọn oniwaasu ijọ Alatako Katoliiki kaakiri gbogbo orilẹ-ede yii ni ko gbagbọ wipe Jesu yoo pada wa ninu ara lẹẹkeji; ida mẹtadinlaadọrun ni o n ṣẹ ibi nipasẹ wundia. Ẹ ronu nipa iyẹn wo! Kini awọn ọmọ wa yoo doju kọ lọjọ iwaju? Ọlọrun, jọwọ fun wa ni igbagbọ naa lẹẹkan si i, eyiti a fi le awọn eniyan mimọ lọwọ ni igba kan ri.

32 Abrahamu … ẹ kiyesi ipa ọna rẹ, bi o ti n goke bọ. Oun jẹ apẹẹrẹ ijọ gan-an. Ohun gbogbo ti Abrahamu ṣe ni o … A ti kiyesi ijọ. Iba ṣe wipe a ni bii ọsẹ kan tabi meji lati wa nihin ni, emi iba fi han yin ni ṣiṣẹ-n-tẹle, wipe ọna kannaa ni ijọ rin. Ami ti o kẹyin ni Ọlọrun, Ọrọ ileri naa, ti o n ba a sọrọ ninu ẹran-ara eniyan - ileri ti o kẹyin ki a to pa aye awọn Keferi run, iyẹn ni Sodomu ati Gomorra.

Ẹ ronu bayi. Tẹlẹ, Abrahamu ni … Ọlọrun ti fi ara han-an ni oriṣiriṣi ami, ati imọlẹ, ati ìrísí, ati ami. Ṣugbọn Ọlọrun ko fi igba kankan tọ ọ wa gẹgẹbi eniyan ri, ki o si sọrọ ni ẹnu ko eti, bi eniyan lati inu eniyan. Ẹ si ranti, ileri naa ti ṣetan lati wa si imuṣẹ. Ti… A o sun Sodomu ni ina. Iṣẹ-iranṣẹ iwaasu ti o kẹyin ti bẹrẹ. Ijọ ti ara si farahan. Billy Graham ode oni si jade lọ lati fa wọn jade.

33 Ijọ ayanfẹ wa - ki iṣe ni Sodomu - a ti pe wọn jade, a ti ya wọn sọtọ. Wọn ni ojiṣẹ kan. Ẹ kiyesi i, ẹgbẹ Abrahamu ni iṣẹ-iranṣẹ iwaasu kan. Ki si ni bayi? Ọlọrun ti O ti n ba a sọrọ tẹlẹ nipa ami, ati irisi, ati ohun gbogbo, O kuku wa farahan bayi. O n fi ara Rẹ han nihin bayi ninu ẹran-ara eniyan, O si mọ ero ti o wa ninu ọkan Sarah lẹyin Rẹ. Abrahamu si wipe, "Ẹlohiimu ni, ẹniti o danikan tó funra Rẹ." Ẹ ranti, kete lẹyin iyẹn, Sodomu jona.

Ẹ ronu nipa rẹ.

34 Ijọ ti lee maa gba ami rẹ ti o kẹyin bayi, ẹyin ọrẹ. Ẹ wo o, a ti … ẹ ti pariwo, ẹ ti ni idalare nipasẹ Luther, isọdimimọ nipasẹ Wesley, awọn akoko nla, ariwo pipa, ayọ yiyọ, ifedefọ, itumọ ede, iwosan atọrunwa.

Ṣugbọn nibo ni a wa bayi? Ọlọrun n sọrọ laarin wa, nipasẹ wa - a gbọ ọ ketekete, gẹgẹbi O ti ṣe nibẹyẹn.

O ṣe ileri lati ṣe e - ohun ti o wa nibẹ niyẹn. Ki iṣe adaṣe tiwa; Bibeli ni o sọ bẹẹ. Jesu sọ wipe Oun yoo ṣe e - lati tun fi ara Rẹ han lẹẹkan si i. Ẹ kiyesi i. Lojukannaa lẹyin eleyi, Abrahamu bẹbẹ fun Lọọti. O si wipe ti Oun ba tilẹ lee ri eniyan mẹwa, Oun yoo da a si, ṣugbọn ko ri iyẹn paapaa. Awọn ojiṣẹ lọ sibẹ, wọn si kọ awọn ojiṣẹ naa.

35 Gẹgẹbi ipade ounjẹ owurọ Billy Graham, nigbati o wa ninu ilu wa - ni Louisville, Kentucky. Mo wa nibi ipade ounjẹ owurọ rẹ. O ni, “Emi yoo lọ sinu ilu kan…” O ni… O gbe Bibeli soke. O jẹ ẹniti o gba Bibeli gbọ gidigidi. O ni, “Emi yoo lọ sinu ilu kan, emi yoo si ṣe isọji. Emi yoo ni ẹgbẹrun lọna ọgbọn awọn eniyan ti o yipada, tabi ti o ṣe ipinnu.” O ni, “Emi yoo pada lọ si ibẹ lẹyin oṣu mẹfa, emi ko si lee ri ọgbọn pere.” O si wipe, “Pọọlu lọ sinu ilu kan, o si yi ẹnikan pada. Nigbati o ba pada wa lẹyin ọdun kan, ẹniti o yipada yẹn yoo ti yi ẹlomiran pada - ọpọlọpọ ẹni iyipada - titi ti yoo fi ni ọgọọgọrun awọn ti a yipada lati ara ẹnikanṣoṣo yẹn.”

O ni, “Ki lo ṣẹlẹ nisisiyi?” O ni, “Ẹyin ọlẹ oniwaasu…” O ni, “Ẹ joko kalẹ, pẹlu ẹsẹ yin lori tabili, ẹ ko jade lọ bẹ awọn eniyan wọnyẹn wo.”

36 Tani emi, emi alaimọkan, lati tako ajihinrere nla naa? Ṣugbọn o wu mi lati ba a sọ ọrọ kan, wipe: “Billy, oniwaasu wo ni o n bẹ ẹniti o gbagbọ nipasẹ Pọọlu wo?” Idi ni wipe Pọọlu mu u jinlẹ titi ti Kristi fi wọ inu rẹ, ti o fi di ina aaye titi di akoko yii. Ki iṣe agbara iwe kika kan, tabi ẹnikan ti o darapọ mọ ijọ, tabi ẹniti a fi iwe kan le lọwọ, tabi ẹniti o jẹ ẹjẹ lati maa wa sinu ijọ; mu wọn wọ inu baptisiimu Ẹmi Mimọ, lẹyinnaa, yoo gbina jẹ. Yoo bi awọn ọmọ. Bawo ni yoo ti ṣe e, nigbati o yagan? Ko lee bi awọn ọmọ ayafi ti oun funra rẹ ba ni iye. Ọna kanṣoṣo ti ohunkohun fi lee tun ara rẹ bi niyẹn - nipa iru iye. Iru iye naa si ni Ẹmi Mimọ, eyiti o wa ninu Kristi, oun naa ni o wa ninu onigbagbọ.

37 A ṣe akiyesi bayi, wipe, ami ti o kẹyin, ti Ọlọrun fi fun Abrahamu ni Ọlọrun ti O jẹ Ọrọ naa. Ẹ ranti, Ọlọrun, ori ileri naa ti a ti ṣe ileri fun-un lati ọjọ pipẹ, O ba a sọrọ ninu ẹran-ara eniyan. Ọkunrin kan duro sibẹ, O n ba a sọrọ, O mọ ero ti o wa ninu ọkan Sarah, oun si wa ninu agọ ni ẹyin Rẹ - ami ti o kẹyin niyẹn.

Ẹ kiyesi i bayi, Oun ti farahan fun-un tẹlẹ ninu ọpọlọpọ ami ati bẹẹ bẹẹ lọ: bi imọlẹ, ina, ati bẹẹ bẹẹ lọ, O farahan fun-un. Ṣugbọn bayi, ẹ kiyesi i. Mo fẹ ki ẹ ṣe akiyesi ohun ti o ṣẹlẹ si awọn tọkọ-taya naa lẹsẹkẹsẹ. Mo lero wipe ẹ ko ni ka mi si were. Ti o ko ba gba eyi gbọ, fi i silẹ. Ṣaa … ṣe ẹ ri i. Ṣugbọn mo kan fẹ sọ ohun ti mo ro wipe o ṣẹlẹ fun yin. Ṣe ẹ kiyesi i?

Njẹ bawo ni Sarah yoo ṣe bi ọmọ yii? O ti pe ọmọ ọgọrun ọdun bayi. Ẹnikan lee sọ pe, “O dara, iyatọ wa ni igba yẹn.” Bibeli sọ pe ile-ọmọ rẹ ti ku, Bibeli si wipe awọn mejeeji ni wọn ti di arugbo kujọkujọ.

38 Ṣugbọn O n ṣe si Sarah ati Abrahamu, bi wọn ṣe n bọ, gẹgẹbi O ti ṣe ileri lati ṣe si iru-ọmọ wọn. O si ti ṣe e! Mo lee fidi iyẹn mulẹ - awọn igbesẹ ti Abrahamu gbe.

Ẹ wo ibiti o wa nisisiyi. Nigbati Ọlọrun wa, ti O si ba a sọrọ gẹgẹbi eniyan, O fi ara Rẹ han fun-un, lẹsẹkẹsẹ, bawo ni Sarah yoo ṣe bi ọmọ yii? Abrahamu ti n gbe pẹlu rẹ, boya o jẹ… O ni ara rẹ ti ku. Bibeli sọ bẹẹ. Ara rẹ ti ku, ile-ọmọ Sarah naa ti ku, ṣugbọn ko ṣiyemeji; o gba a gbọ sibẹ.

Ẹ wo o bayi. Ti Sarah… Aarin ọkunrin ati obinrin ni mo wa, ki ẹyin arabinrin dariji mi. Ẹ maa n feti si dokita yin, emi si jẹ arakunrin yin. Ṣugbọn ẹ kiyesi i bayi. Sarah, ni ọmọ aadọrun ọdun, ti di arugbo ju ati la irora ibimọ kọja. Ọkan rẹ ko lee gbe e. Ẹ mọ bẹẹ. Ohun miiran tun niyi, omi ọyan rẹ ti gbẹ. Wọn ko ni igo ti a fi n fun ọmọ ni ounjẹ ni igba yẹn, ṣe ẹ mọ - o nilati jẹ iya ti o ni omi ninu ọyan rẹ. Ẹ kiyesi i. Nitorinaa, bawo ni yoo ti ṣe e? Bawo ni yoo ṣe bi ọmọ yii? Ile-ọmọ rẹ ti ku, ara rẹ ti ku pẹlu; ara Abrahamu naa ti ku.

39 Njẹ ẹ mọ ohun ti O ṣe? O yi wọn pada. O yi wọn pada si ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin. Mo lee fidi iyẹn mulẹ. O sọ wọn di ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin, O sọ wọn di ọdọ pada. Ah, ileri iyanu ni! O lee wipe, “Ah, Arakunrin Branham…” O dara, duro na. Maṣe … iwọ ṣaa duro na. Eyi lee dun awọn olofin diẹ, ṣugbọn mo fẹ ki ẹ ri eleyi bayi, fun iṣẹju kan. A n kọ wa ni ẹkọ yii gẹgẹbi ile-ẹkọ Ọjọ Isimi. O pada sọ wọn di ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin, bii ọmọ ogun ọdun.

40 Ẹ wo Abrahamu bayi, o ti di arugbo - awọn irun imu rẹ ṣàn wa si isalẹ, ara rẹ ti dabi oku, ọwọ rẹ ko ni okun mọ; Sarah pẹlu, oun naa fi iborun kọ ọrun rẹ, pẹlu fila kekere kan ni ori, iya arugbo ti o n fi ọpa rin. Mo lee ri wọn ni owurọ ọjọ keji. Abrahamu ti ẹyin rẹ ti tẹ, pẹlu irun funfun lori, Sarah wipe, “Abrahamu, olufẹ! Ki lo ṣẹlẹ, tirẹ … irugbọn rẹ ma ti pada di dudu!”

“Ki lo ṣẹlẹ, Sarah, oju tirẹ naa ma n dan, bi o ṣe ri tẹlẹ. Ẹrẹkẹ rẹ ti yọ, o si n dan.” Ki oorun to wọ ni irọlẹ ọjọ keji, o ti pada di ọdọmọbinrin, oun naa ti pada di ọdọmọkunrin.

O lee wipe, “Isọkusọ niyẹn, Arakunrin Branham.”

41 Bẹẹni, otitọ ni o ṣẹlẹ! Bẹẹni - ileri iyanu ni, o si jẹ apẹẹrẹ fun iru-ọmọ alade Abrahamu ti o n bọ laipẹ. Ẹ ranti. Ṣe ileri ni? Bẹẹni, a o pa wa lara da. A yi wọn pada si ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin, o n fi ohun ti ijọ yoo ṣe han, ani ohun ti iru-ọmọ alade naa yoo ṣe. O ni, "Ṣe ileri niyẹn?" Tẹssalonika Kinni, 4:17: ipe Ọlọrun yoo dun, a o si pa wa lara da; ni iṣẹju kan, ni iṣẹju aaya, a o gba wa lọ soke papọ.

Kini? Ara rẹ, ara wọn nilati yipada ki wọn lee ri ọmọ naa gba. Ara kiku wa yii, ara ibajẹ wa yii nilati yipada fun wa lati gba Ọmọ naa, nitori a o gba wa lọ soke. Ara wa nilati yatọ si eyi, nitori a o gba wa lọ soju ọrun lati pade Rẹ. Amin! O ba Iwe Mimọ mu, ṣe o ye yin. A yi wọn pada.

Bi a o ba pade Oluwa ni oju ọrun, a ko lee pade Rẹ pẹlu iru ara yii, nitori ti aye ni. Ṣugbọn a o gba ara kan - halleluyah! - eyiti yoo goke lọ ninu igbasoke.

42 Ohun ti o dun mọ ni nipa rẹ ni wipe, o ti sunmọ tosi. A ri gbogbo ami rẹ ti o n farahan - ki yoo pẹ mọ. Lowurọ ọjọ kan, iyipada yoo ṣẹlẹ.

43 Ṣugbọn ẹ ranti, iru-ọmọ alade yẹn nikan ni yoo wa fun. Bibọ Jesu yoo jẹ aṣiiri tobẹẹ, ti awọn eniyan ti o kù ki yoo mọ ohunkohun nipa rẹ.

Njẹ ẹ mọ wipe wọn ki yoo pọ. "Bi o ti ri ni igba Noah, nigbati a fi omi gba ẹni mẹjọ la, bẹẹ ni yoo ri ni igba bibọ Ọmọ eniyan." "Hiha ni ẹnu ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, ṣugbọn awọn diẹ ni yoo ri i."

O lee wipe, "Ọkẹ aimoye ni yoo wa nibẹ." Dajudaju, ṣugbọn wọn yoo jẹ gbogbo awọn ti a ti ra pada ni gbogbo iran. Ṣugbọn ibi igbasoke yẹn, nibi ti a wa bayi…

44 Kini yoo ṣẹlẹ lọjọ kan? Wọn yoo sọ pe, "Njẹ o mọ, a ti wa ni akoko ipọnju. Mo ro wipe a o gba ijọ lọ soke ṣaaju igba ipọnju ni."

Otitọ niyẹn - kii ṣe ijọ; iyawo ni. Ijọ yoo la igba ipọnju kọja; ṣugbọn kii ṣe iyawo. Rara, sà. A ti ra a pada. Ko si ohun ti a o wẹ nù lara rẹ - o ti mọ́ sibẹ. Ẹmi Mimọ ti wọ inu rẹ, O si ti wẹ ẹ mọ, O ti mu gbogbo idọti ati ikuuku aye kuro. O gba Ọrọ yẹn gbọ, o si di ara Rẹ. Bẹẹni. Laisi Ẹmi Mimọ, ohunkohun ko lee ṣẹlẹ. Inu ijọ ni iyawo ti jade. Nibẹ … eyi ti o ṣeku ninu iru obinrin naa yoo la igba ipọnju kọja.

45 Ṣe ẹ mọ, ni igba kan, lẹyin gbogbo Iwe Mimọ - Isaiah, Malaki 3, Isaiah 40 - n sọtẹlẹ nipa bibọ Johanu Onitẹbọmi, Johanu wa ni ibamu pẹlu awọn ẹsẹ Iwe Mimọ naa. Awọn ọmọ-ẹyin tilẹ tọ Jesu wa, wọn wipe, "Eeṣe ti awọn akọwe fi sọ [Iwe Mimọ], wipe Elijah yoo tete kọkọ de?

O ni, "O ti de na, ẹ ko si mọ ọ. O ti de, wọn si ti ṣe ohun ti o yẹ ki wọn ṣe si i; ẹ ko si mọ ọ."

Iyẹn yoo ṣẹlẹ lọjọ kan. O lee wipe, "Igbasoke nkọ?"

O ti kọja na, ẹ ko si mọ ọ. "Ẹni meji yoo wa ninu ibusun kan. A o mu ọkan; a o fi ekeji silẹ." Njẹ ẹ mọ, ọpọlọpọ awọn eniyan ni wọn n poora ninu aye lojoojumọ, ṣe ẹ mọ bẹẹ. Wọn ko ni akọsilẹ fun-un. Ẹ ronu nipa rẹ o - iru ibanujẹ naa! - wipe awọn eniyan yoo maa waasu lọ, wọn yoo si maa gbagbọ wipe a n gba wọn la.

46 Noah wọ inu ọkọ, ilẹkun si ti lẹyin rẹ lati ọwọ Ọlọrun. Oorun n yọ, o si n wọ fun ọjọ meje ki ohunkohun to ṣẹlẹ. Awọn eniyan si n tẹsiwaju lati maa waasu, wọn n ṣe yẹyẹ, ati ohun gbogbo bẹẹ, wọn ko mọ wipe aanu kanṣoṣo ti wọn ni, a ti ti ilẹkun mọ ọ. Ẹ ronu o! Awọn oniwaasu yoo maa kọ awọn oniwaasu ni ẹkọ sibẹ, wọn yoo si maa ran wọn jade, iru nkan bẹyẹn yoo maa ṣẹlẹ, bi ẹni wipe ijọ n tẹsiwaju - bẹẹni ko si aanu mọ rara, ko si ohunkohun, a ti ja wọn kuro patapata. Igbasoke ti kọja. "Ẹniti iṣe ẹlẹgbin, ki o maa jẹ ẹlẹgbin sibẹ." Ohun ti Iwe Mimọ sọ niyẹn. O ti ṣẹlẹ na, ẹ ko si mọ ọ.

Ẹ ronu nipa iyẹn ni aṣalẹ yii, ẹyin ọrẹ, ki ẹ si kiyesi ohun ti o n ṣẹlẹ.

47 Ko si ohunkohun ni aye yii ti o lee tu ọ ninu bikoṣe Ọrọ Ọlọrun, ṣe o ye yin. Ko si ireti miiran - ni orilẹ-ede rẹ, tabi ni ibomiran. Idin ti jẹ wa kan eegun. Ẹ mọ bẹẹ. Ijọba aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ ti jẹ wa kan eegun. O nilati ri bẹẹ. Ẹ ko lee da a duro. Bibeli sọ wipe bẹẹ ni yoo ri. Nitorinaa, ẹ ko lee da a duro, ko ju bẹẹ lọ. Ẹ mura silẹ fun igbasoke. Ohun kan ti a lee ṣe niyẹn.

48 Tẹssalonika… Tẹssalonika Kinni, 4:17 sọ pe a o pa wa lara da bii ti Abrahamu, a o si gba wa soke ninu ara miiran. A nilati yi ara ogbo Abrahamu pada. Bẹẹ ni a o yi tiwa naa pada lati lee mu ileri naa ṣẹ. A o pa wa lara da.

O lee wipe, "Ara gbigbo yii kẹ?" Mo fẹ … Mo n sọrọ ni Kiwanis nibi yii ni igba kan, dokita kan si jade sita. O ni, "Ọgbẹni Branham," o ni, "mo mọ riri ọrọ ti o sọ, ṣugbọn o mọ wipe emi ko lee gba iyẹn gbọ … emi ko lee gba ohunkohun gbọ ayafi ti a ba fidi rẹ mulẹ nipa imọ-ijinlẹ - nipa ìbí wundia yẹn ati iru awọn nkan bẹyẹn, nipa wipe O jẹ Ọlọrun."

Mo ni, “Ko buru, iwọ ki yoo gba a gbọ laelae, nitori o ko lee fidi Ọlọrun mulẹ nipa imọ-ijinlẹ. O nilati gba a gbọ nipa igbagbọ - nipa igbagbọ ni.”

O ni, “O dara, emi ko gba ohunkohun ti ki iṣe imọ-ijinlẹ gbọ.”

Mo ni, “Ṣe o ni iyawo?”

O ni, “Bẹẹni, sà.”

Mo ni, “Ṣe o fẹran iyawo rẹ?”

O ni, “Dajudaju, mo fẹran rẹ̀.”

Mo ni, “Fi ohun ti ifẹ jẹ han mi nipa imọ̣-ijinlẹ. Mo fẹ ra diẹ, ti o ba lee sọ ile-itaja oogun ti wọn ti n ta a. Mo nilo rẹ gidigidi.” Mo ni, “Mo…” Ṣe ẹ ri i, ohun ti o rọrun ni.

49 Mo ni, “Mo fẹ beere ohun kan lọwọ rẹ. Ni bayi. Ṣe erupẹ ilẹ ni a fi mọ wa?”

O ni, “Bẹẹni, sà.”

Mo ni, “A n gba erupẹ yẹn nipa jijẹ ounjẹ ti o wá lati inu ilẹ. Iye ewebẹ si ni, ati awọn nkan miiran.” Njẹ ẹ mọ, ohun ti o ti ku nikan ni awa fi n wa laaye. Ti o ba wa laaye, nkankan nilati ku ki o lee wa laaye nipa ti ara. Ti o ba jẹ ànàmá, o ku. Ti o ba jẹ ẹran, maaluu ku. Ti o ba jẹ ẹran ẹlẹdẹ, ẹlẹdẹ ku. Ti o ba jẹ eweko, o ku - iye kan ni. A wa laaye ninu ara yii nipa ohun kan ti o ku - oku nkan. Njẹ iyẹn ko ha mu ọgbọn dani bi, ẹyin ọrẹ, wipe nipa ohun ti o ku fun ọ nikan ni o fi lee wa laaye titi ainipẹkun? Kristi ku, bẹẹni, O pada jinde lati fihan wipe Ọlọrun ni Oun.

Ẹ kiyesi i bayi.

50 Mo ni, “Dokita, ti mo ba jẹ ounjẹ, ni gbogbo igba ti mo ba jẹ ounjẹ, o n lọ sinu ara mi, o si n di ẹjẹ ninu ara mi.”

O ni, “Bẹẹ ni.”

“Ni gbogbo igba ti mo ba n jẹun, mo n sọ iye mi di ọtun.”

O ni, “Otitọ niyẹn - ẹjẹ titun.”

51 Mo ni, “Mo fẹ beere nkankan lọwọ rẹ. Nigbati mo jẹ ọmọ ọdun mẹrindinlogun, mo n jẹ agbado, ati ẹwa, ati ànàmá, ati ẹran gẹgẹbi mo ti n jẹ ẹ bayi naa. Ni gbogbo igba ti mo ba jẹun, mo n sanra si i, mo si n lagbara si i. Lẹyinnaa, nigbati mo to bii ọmọ ọdun mejilelogun… Gbogbo eniyan, ko si bi o ṣe jẹun to, tabi bi ounjẹ rẹ ṣe dara to, iwọ yoo maa dagba si i, aarẹ yoo si maa mu ọ si i. Ti mo ba n da omi lati inu ife yii si eyi, ti mo da a de ilaji, ti mo si tun n da a si i lẹyin ti o ti de ilaji; dipo ki o maa kun si i, nṣe ni o n lọ si isalẹ si i - fihan mi nipa imọ-ijinlẹ, bi iyẹn ṣe n ṣẹlẹ.”

Bawo ni o ti jẹ, ti o jẹ wipe mo n jẹ ounjẹ kannaa, mo n sọ iye mi di ọtun lojoojumọ ni ibamu pẹlu … o fihan; imọ-ijinlẹ fidi rẹ mulẹ wipe mo n sọ iye mi di ọtun nigbati mo ba n gba ẹjẹ titun, iru ẹjẹ kannaa ti mo gba nigbati mo jẹ ọmọ ọdun mẹrindinlogun. Ṣugbọn eeṣe ti o jẹ wipe nigbati mo le ni ogun ọdun, ko si ohun ti mo lee jẹ, mo n lọ silẹ si i ni - mo n gbó si i, mo n gbó si i, mo tun n gbó si i, mo si n lọ silẹ ni gbogbo igba. Dipo ki o maa kún mi si i gẹgẹbi o ti ṣe ni igba yẹn; ni bayi, nṣe ni o n mu mi lọ silẹ. Adehun ni, ohun ti o jẹ niyẹn.

52 Ṣugbọn Ọlọrun ya aworan kan. O mu ọ nigbati o jẹ ọmọ ogun ọdun o lé diẹ. Ti ohunkohun ko ba ṣe idiwọ… Gẹgẹbi ọmọkunrin arọ ti o joko si ibi yii, bi igbati poporo ọka ba bẹrẹ si yọ, ti nkankan si joko le ori rẹ, ti o jẹ ki o wọ si ẹgbẹ kan. Ti o ba lee gbe ohun ti o jẹ ki o wọ si ẹgbẹ kan yẹn kuro, poporo ọka naa yoo naro taara. O nilati ṣe bẹẹ, ko ju bẹẹ lọ. Ẹ kiyesi i, ti ohunkohun ko ba ṣe idiwọ fun-un, bi o ṣe ri niyẹn: ọdọmọbinrin ti o rẹwa, ọdọmọkunrin ti o rẹwa, iwọ ati ọkọ rẹ jọ duro papọ, Adamu ati Eefa ode oni, lati ibẹrẹ wa. Ọlọrun wipe, “Awọn niyẹn. Ni bayi, iwọ iku, lọ ba wọn. O lee maa mu wọn bayi, ṣugbọn o ko lee mu wọn patapata ayafi ti mo ba pe.” Njẹ kini bayi? Aworan odi ni.

Akiika! Ṣe ẹ ri i,

53 ohun ti O ṣe si Sarah ati Abrahamu gan-an niyẹn. O mu ọjọ ogbó kuro. Ogbó jẹ ami iku, ki yoo si si ami iku ni ọrun. Gbogbo iranti iku ni a o mu kuro, ki yoo si ọjọ ogbo nibẹ. Gbogbo wa yoo jẹ ọdọ. Aworan kan ti Ọlọrun ya jade ni igba ọdọ rẹ ni. Ni bayi, Ọlọrun ti mu Abrahamu ati Sarah, O si da wọn pada si igba ọdọ wọn. Bi o ṣe ri niyẹn.

54 Ẹri miiran ti mo fẹ fi han yin niyi. Mo ro wipe iyẹn ko dara to. Mo ṣaa nilati … ẹ ko gba iyẹn gbọ. Ko buru,

ẹ jẹ ki n beere lọwọ yin … ẹ jẹ ki n fi nkankan han yin. Ẹ jẹ ki n fihan yin wipe wọn yipada. Ẹ kiyesi i bayi. Ẹ wo ibi ti wọn wa loju aworan agbaye nigbati Ọlọrun farahan fun wọn, ni tosi Sodomu. Kete lẹyin iyẹn, wọn rin irin-ajo ti o fẹrẹ to ọọdunrun maili lọ si Gerari. Irin-ajo nla niyẹn fun baba arugbo ati iya arugbo kan. Baba arugbo yii niyi, irun imu rẹ ṣan wa si isalẹ, o fi ọpa tilẹ. Iya agba naa tun niyi, ṣe ẹ mọ, pẹlu fila kekere kan ni ori, o n rin bọ ni ẹyin rẹ, o n gbe igbesẹ inṣi mẹrin tabi marun-un bi o ṣe n lọ.

55 Wahala ibẹ wa ni pe, nigbati wọn de Gerari, Abimeleki wa nibẹ. Ọba kan ti o n wa ololufẹ kan. Pẹlu gbogbo awọn arẹwa obinrin ti o ni nibẹyẹn, awọn ọmọbinrin Filistini - nigbati o ri Sarah, o fẹran rẹ, o si fẹ fi ṣe aya rẹ. Ṣe bẹẹ ni? Ha, ha!

Ah, arakunrin, Bibeli dabi lẹta ifẹ. O nilati ka awọn adiitu ibẹ, ki o lee mọ ohun ti o tumọ si. Ọlọrun sọ wipe Oun fi pamọ loju awọn ọlọgbọn ati amoye, Oun si fihan fun awọn ọmọ-ọwọ ti o ṣetan lati kọ ẹkọ.

56 Nigbati mo ba jade lọ fun iwaasu, iyawo mi yoo kọ iwe si mi. Mo fẹran rẹ, oun naa si fẹran mi. Yoo wipe, “Bill ọwọn: Ni alẹ oni, mo ṣẹṣẹ gbe awọn ọmọ lọ sori ibusun ni, mo si ṣiṣẹ loni…” Mo ri ohun ti o n (ka), ohun ti o n kọ; ṣugbọn ẹ wo o, mo fẹran rẹ tobẹẹ, mo mọ awọn adiitu inu iwe naa. Mo mọ ohun ti o n sọ. Ko nilo lati sọ fun mi - mo mọ, nitori mo mọ awọn adiitu ti o wa nibẹ.

Bi o ṣe ri pẹlu Ọlọrun niyẹn. A ko gbiyanju lati kẹkọ lati inu iwe-iroyin kan, tabi lati inu ẹkọ-ẹsin kan; ṣugbọn a ni ifẹ Rẹ! Gba a sinu ọkan rẹ nitootọ - a tan ifẹ Ọlọrun kalẹ ninu ọkan wa nipa Ẹmi Mimọ. Lẹyin eyi, lọ maa ka Bibeli. Iwọ yoo ri i wipe awọn adiitu inu rẹ ye ọ. O mọ ohun ti O n sọ. Ko sọ iyẹn jade gẹgẹbi ọrọ. Jesu dupẹ lọwọ Baba nitoriti O ti fi awọn nkan wọnni pamọ kuro loju awọn ọlọgbọn ati amoye.

Ko si ẹlomiran ti o lee ka lẹta iyawo mi bẹyẹn, nitori mo fẹran rẹ bẹyẹn, ṣe o ye yin. Bi o ṣe maa n kọ iwe si mi niyẹn. Bi Ọlọrun ṣe n kọ iwe si ọ niyẹn - adiitu ni. Iwọ ka a.

57 Sarah niyi bayi. Dajudaju. O sọkalẹ lọ si ibẹyẹn. Njẹ ẹ lee fi oju inu wo iya agba kan, ṣe ẹ mọ, pẹlu gbogbo awọn arẹwa ọdọmọbinrin ti o wa ni ilẹ Filistini (ẹgbẹ) orilẹ-ede, Gerari. Abimeleki wa nibẹ. Ọdọmọkunrin ọba ti o rẹwa lati wò ni, o si n fẹ iyawo kan. O wo ayika. Wọn rẹwa ninu ohun gbogbo. Ṣugbọn o ri iya agba kan ti o n bọ, ṣe ẹ mọ - ti o n gbọn, ti ara rẹ ko balẹ, o n bọ. O ni, “Ẹniti mo ti n duro de niyẹn! Oun niyẹn! Ah!”

58 Abrahamu wipe, “Mo bẹ ọ, Sarah, ṣe oore yii fun mi. O rẹwa lati wo loju, ṣe o mọ.” O ni, Nigbati o ba de ibẹyẹn, sọ wipe ẹgbọn rẹ ni mo jẹ, emi yoo sọ wipe arabinrin mi ni o jẹ, nitori ti o ko ba ṣe bẹẹ, wọn yoo pa mi, wọn yoo si mu ọ, ṣe o ye ọ.“

O ko lee fẹ iyawo meji papọ lẹẹkannaa ni igba yẹn. Nitorinaa, a… Oun ko lee ni ọkọ meji lẹẹkanaa ni igba yẹn. Lọjọ kan, emi yoo waasu lori iyẹn. Ẹ n sọrọ nipa “Iru-ọmọ Ejo” wipe o da nkankan silẹ - ẹ duro de igba ti eleyi yoo jade sita.

O dara, ẹ ranti bayi

59 a ri i wipe nigbati o ri ẹni yii ti o n bọ - iya arugbo kan - Abimeleki ni ifẹ rẹ, o si mu u, o fẹ fi ṣe iyawo rẹ. Ẹ ronu nipa iyẹn. Ṣe ẹ ri i wipe O yi wọn pada? Dajudaju, O nilati ṣe bẹẹ.

Bibeli jẹ iwe ifẹ ti Ọlọrun kọ si wa. O fi pamọ loju awọn ọlọgbọn ati amoye, O si fihan fun awọn ọmọ-ọwọ, awọn ti o ṣetan lati kọ ẹkọ. O fi bibọ Rẹ pamọ. O fi Jesu pamọ fun awọn Farisi - awọn akẹkọ Iwe Mimọ. A ko ni iru wọn loni. Ko si bi wọn ṣe jẹ akẹkọ to, wọn ko da Oun mọ. A fi i pamọ. Bibeli sọ wipe a fi i pamọ.

60 Ṣe ẹ mọ wipe Bibeli sọ pe a o fi awọn alufaa ọjọ oni naa pamọ bakannaa? “Olorikunkun, ọlọkan giga, olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ, ọdalẹ, olufisun eke, alainitẹlọrun, olukẹgan awọn ẹni rere; wọn ni…”

O sọ pe, “Ijọba Aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ niyẹn.”

Rara, rara. “… wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn wọn n sẹ́ agbara rẹ. Yẹra kuro lọdọ awọn wọnni,” ṣe ẹ ri i. Bẹẹ ni. “Iru awọn wọnyi ni wọn n lọ lati ile de ile, ti wọn si n ṣi awọn obinrin lọna, awọn ti a di ẹru ifẹkufẹ le lori,” ati bẹẹ bẹẹ lọ.

Ẹ kiyesi i.

61 A ri Abrahamu nibẹ. Abimeleki wá, o ni, “Ẹniti mo ti n duro de lati igba yii wa niyẹn.” O ni ki awọn ọmọbinrin rẹ lọ mu u wa, ki wọn mu jade lọ, ki wọn ṣe e lọṣọ, ki wọn si jẹ ki o dabi ayaba. Ni alẹ ọjọ yẹn… Mo fẹ ki ẹ kiyesi ibi yii, oore-ọfẹ Ọlọrun si wolii Rẹ. Eyi lee ya ọ lẹnu diẹ, ṣugbọn otitọ ni. Ko si bi o ti wu ki o ri; iwọ ṣaa wo ohun ti Bibeli sọ.

62 Ẹ ri Abimeleki yii, o ronu pe, “Ni ọla, emi yoo fẹ ọmọbinrin Heberu ti o rẹwa yii. O ti wa ninu iyara bayi.

Awọn ọmọ-ọdọ mi obinrin si n fi ikunra oloorun didun pa a lara, wọn n ṣe irun rẹ ki o rẹwa, wọn si n ṣe e lọṣọ.” Njẹ ẹ lee fi oju inu wo o, iya arugbo, ọmọ aadọrun ọdun, ti wọn n ṣe ọṣọ fun-un lati lee fẹ ọba ti o jẹ ọdọ?

A ri i wipe bi wọn ṣe n ṣe arẹwa ọmọbinrin Heberu yii lọṣọ… O lọ wẹ, o si dubulẹ. O na ẹsẹ rẹ lẹyin ti o ti gbadura tan, o dubulẹ, o ni, “Kai.”

63 Njẹ ẹ lee ro o wipe Abrahamu yoo ta iru ọgbọn bẹyẹn? Ẹniti o sọ iru nkan bẹyẹn nipa iyawo rẹ? Ojo eniyan ni! Abrahamu ṣe bẹẹ. Oun niyẹn, o joko si ita, lẹyin ti o ti ṣe iru nkan bẹyẹn.

Ẹ kiyesi i. Abimeleki - ni alẹ ọjọ yẹn, Oluwa fara han-an loju ala, O wipe, “Oku eniyan ni ọ.” O ni, “Iyawo oniyawo ni o lọ mu.”

Ó ni, “Oluwa, O mọ otitọ ọkan mi.” O ni, “Ó sọ fun mi wipe arakunrin oun ni, oun naa si sọ fun mi wipe arabinrin oun ni.”

O ni, “Mo mọ otitọ ọkan rẹ. Idi niyẹn ti n ko fi jẹ ki o dẹṣẹ si mi,” ṣe ẹ ri i. “Ṣugbọn iyẹn … wolii mi ni ọkọ rẹ. [Ẹ wo oore-ọfẹ Rẹ si wolii Rẹ, bi o tilẹ jẹ wipe o wa ninu ikuna, ṣe ẹ ri i.] O ni, ”Wolii mi ni. Emi ki yoo gbọ adura rẹ. Lọ da iyawo rẹ pada fun-un ki o si jẹ ki o gbadura fun ọ. Ti o ko ba ṣe bẹẹ, gbogbo orilẹ-ede rẹ ti tan niyẹn - gbogbo ile-ọmọ ni mo ti sé.“

Ẹ ronu nipa iyẹn! Ohun ti O sọ gan-an niyẹn. Eniyan rere ni Abimeleki, o si bẹru Ọlọrun. Bẹẹni, sà.

64 Njẹ ẹ ri ohun ti oore-ọfẹ Ọlọrun ṣe? Wolii Rẹ joko si ita, o fi iyawo rẹ fun ẹlomiran lati fẹ ẹ - o si n foju sọna fun ileri ọmọ kan, ati iru awọn nkan bẹyẹn - oore-ọfẹ Ọlọrun si duro ti Ọrọ naa, laibikita ohun ti o ṣẹlẹ. Bẹẹ ni. “Wolii mi ni ọkọ rẹ, emi ki yoo gbọ adura rẹ. Ko si bi o ṣe jẹ olododo to, bi o ṣe dara to, tabi bi o ṣe jafafa to, bikoṣepe o ba gbadura fun ọ, oku eniyan ni ọ.”

Nitorinaa, o da Sarah pada. Kai!

65 Lẹyinnaa ni Isaaki farahan. Ni ipari bayi, kiakia, mo fẹ de ibikan. Isaaki farahan, a si mu ileri naa ṣẹ.

Lẹyin ti Isaaki de - ọmọdekunrin kan, o to bii ọmọ ọdun mejila, ati bẹẹ bẹẹ lọ - Ọlọrun ṣe idanwo onipele meji fun Abrahamu. Lẹyin ti O ti dan-an wo fun ọdun mẹẹdọgbọn, lẹyin eyi ni O ṣe idanwo onipele meji fun-un. O ni, “Abrahamu, mo fẹ ki o mu ọmọ rẹ bayi, ọmọ rẹ kanṣoṣo, ki o mu u lọ sori oke kan ti Emi yoo fi han ọ ninu iran yii. Mo fẹ ki o mu u lọ sori oke yẹn, ki o si fi rubọ.”

66 O wipe … ko kọ lati ṣe bẹẹ. O dide ni owurọ ọjọ keji lẹyin ti Oluwa ti ba a sọrọ, o di ẹru le ibakasiẹ, o mu igi idana diẹ ati awọn nkan miiran, o si lọ pẹlu ibakasiẹ naa. O rin irin-ajo ọjọ mẹta. O de ibẹ, o si wo okeere rere lẹyin ti o ti rin irin-ajo ọjọ mẹta. Ibi ti Abrahamu wa niyi. Irin-ajo ọjọ mẹta … nigbati… Awọn eniyan ko ni ọkọ ayokele ti awa ni loni. Bẹẹni ẹniti ara rẹ da ṣaṣa lee rin maili mẹẹdọgbọn ni ọjọ kan. Nibo ni o lọ, ninu aginju yẹn?

O wipe, “Ẹyin ẹ duro sibi.” (Mo fẹran eleyi nipa Abrahamu.) O sọ fun awọn iranṣẹ rẹ, o ni, “Ẹyin ẹ duro sibi pẹlu awọn ibakasiẹ, emi ati ọmọ mi yoo goke lọ jọsin nibẹyẹn; a o si tun pada wa.”

Bawo ni yoo ti ṣe e, nigbati o jẹ wipe o n lọ lati pa a ni? Ọlọrun sọ fun-un, wipe, “Goke lọ sibẹyẹn, ki o si gba ẹmi rẹ̀.”

67 Ṣugbọn kini Bibeli sọ ni Roomu 4? “Abrahamu mọ wipe oun gba a bii lati inu oku, o si ni idaniloju wipe Ọlọrun lee ji i dide kuro ninu oku, lati ibiti o ti gba a gẹgẹbi apẹẹrẹ.”

O ni, “Ẹyin ẹ duro sibi.”

Bi yoo ti ṣe e, emi ko lee sọ fun yin. Ṣe o lee ronu nipa iyẹn, iwọ arabinrin ti o gbe ọmọde kan dani, ati iwọ iya ti o wa ninu kẹkẹ arọ, iwọ ọmọdekunrin ti o wa nibẹyẹn, ati iwọ baba ti o wa nibi yii? Emi ko mọ bi yoo ti ṣe e. Ko tilẹ ye mi bi yoo ti ṣe e, ṣugbọn yoo ṣe e - nitoriti O ṣe ileri wipe Oun yoo ṣe e, iyẹn ti a ba gba a gbọ. O ṣe e fun awọn ẹlomiran, ṣe ẹ ri i.

68 “Emi ati ọmọ naa … emi ati ọmọ naa yoo pada wa,” ṣe ẹ ri i. “Ẹyin ẹ duro sibi yii, awa yoo lọ jọsin.” O gbe igi idana le Isaaki lori, apẹẹrẹ wipe Kristi ru agbelebu ara Rẹ. O de ori oke naa; Isaaki fura.

O si wipe, “Baba…”

O ni, “Emi niyi, ọmọ mi.”

O ni, “Eetiri, pẹpẹ niyi, ina niyi, igi idana niyi; ṣugbọn ọdọ-aguntan irubọ da?”

Ẹ feti si awọn ọrọ wọnyi bayi, eyiti o jade lati ẹnu Abrahamu. "Ọmọ mi, Ọlọrun yoo pese ọdọ-aguntan ẹbọ funra Rẹ." Itumọ iyẹn ni wipe, ẹbọ ti Ọlọrun pese - Jehofa-jire, Oluwa yoo pese ọdọ-aguntan.

69 Nigbati o de ọwọ rẹ̀, ti o gbe e le ori pẹpẹ…

Ẹ ronu bi akoko yẹn yoo ṣe ri, lẹyin ti o ti duro de ọmọ naa fun ọdun mẹẹdọgbọn; ti Ọlọrun si ni ki o pa ohun kanṣoṣo ti o ti n duro de ni gbogbo ọdun yii run. O ti di ẹni ẹgan laarin awọn eniyan - wọn n fi rẹrin. Ọlọrun tun wa sọ wipe, "Pa ohun kanṣoṣo naa run, eyiti yoo fun ọ ni ireti kanṣoṣo wipe a o mu ọrọ Mi ṣẹ ninu rẹ. Emi ni mo fun ọ ni ọmọ naa. O ti di ọmọ ọdun mejila, gbogbo wọn ti mọ ọ, sibẹ emi yoo ṣe ọ ni baba orilẹ-ede pupọ; ṣugbọn lọ pa ọmọ rẹ naa." Njẹ ẹ lee fi oju inu wo iyẹn? Ọlọrun n fihan fun wa wipe, ko si ohun ti ẹnikẹni lee sọ, tabi ohunkohun ti o lodi si Ọrọ yẹn - iwọ kọ lati wo o. Iru-ọmọ Abrahamu tootọ gba iyẹn gbọ.

"Pa ọmọ yẹn run."

70 Abrahamu gbe e le ibẹ. Ẹ lee ro o wo - o fi ọwọ gba irun rẹ sẹyin kuro ni oju rẹ, oju rẹ si n wo oke, ete rẹ n gbọn, o ri ọbẹ nla naa ti o ti ọwọ baba rẹ jade… Ẹ ronu nipa baba kan! O fi ori rẹ lelẹ, o si fa ọrun rẹ si ẹyin, ki o lee fi ọbẹ naa dumbu ọrun rẹ, ni igbọran si Ọlọrun.

Bi o ti wu ki o ri, o ni, "Mo gba a bii lati inu oku; Ọlọrun lee ji i dide." O gbe ọbẹ naa soke, o si n gbe e bọ wa si ilẹ, Ẹmi Mimọ si da ọwọ rẹ duro.

O ni, "Abrahamu, Abrahamu."

O ni, "Emi niyi."

O ni, "Da ọwọ rẹ duro." O ni, "Bayi, mo mọ wipe o fẹran Mi, o si gba Mi gbọ, nigbati o ko tilẹ … o ṣetan lati fi ọmọ rẹ kanṣoṣo silẹ."

71 Ni akoko yẹn, agbo kan fi iwo rẹ ha pantiri ni ẹyin rẹ. Mo fẹ beere ohun kan lọwọ rẹ, arakunrin, arabinrin. Nibo ni agbo yẹn ti wá? Ẹ wo o. O kuro laarin ilu, o wa ninu igbo ni irin ọjọ mẹta, nibiti awọn kiniun, ikooko, ajako, ati oriṣiriṣi awọn ẹranko buburu ati awọn nkan miiran wa, eyiti o lee pa agbo naa ni kiakia. Ẹ tun wo o, ori oke patapata ni o wa, nibiti ko si omi. O si ti ṣa awọn okuta ni ayika ibẹ, ti o fi ṣe pẹpẹ, agbo naa ko si si nibẹ. Ṣugbọn nigbati Ọlọrun nilo ọkan, o wa nibẹ. Kii ṣe iran - o gun-un ni ọbẹ, ẹjẹ si jade lara rẹ. O ku.

Ọlọrun fi ọrọ ṣẹda rẹ ni iṣẹju yẹn gan-an ni, Abrahamu si mu u kuro ni iṣẹju ti o tẹle e, ṣe ẹ ri i. Jehofa-jire, Oluwa yoo pese ọdọ-aguntan fun ara Rẹ.

72 Ko … ṣee ṣe fun agbo naa lati wa nibẹ! Bi ẹnikẹni ba mọ nipa aguntan ninu igbo - ninu igbo kijikiji bi iyẹn - nibiti awọn ẹranko buburu wa, ti yoo pa a kiakia; ko lee si nibẹ. Ni ṣonṣo ori oke, nibiti ko si omi, ko si koriko tabi ohunkohun nibẹ… Bẹẹni ko si nibẹ ni iṣẹju melo kan ṣaaju igba yẹn. Ni iṣẹju ti Ọlọrun nilo agbo yẹn, o wa nibẹ. O fi ọrọ ṣẹda rẹ̀.

73 Gẹgẹbi O ti farahan fun-un nibẹyẹn - Ẹlohiimu. O nilo ara kan lati fi wa si aye, nitorinaa, O ko imọlẹ iṣẹda jọ, ati epo rọbi ati bẹẹ bẹẹ lọ, o si bọ sinu rẹ. Ṣe ẹ ri i, Ọlọrun ni! Bi yoo ti ṣe iwọ naa niyẹn. Lẹyin ti o ki yoo ju eeru ẹkun sibi kan lọ, Oun yoo sọrọ, iwọ yoo si wa nibẹ. Yoo pe orukọ rẹ, iwọ yoo si dahun - iru-ọmọ Abrahamu. Iru kini … a mu ileri naa ṣẹ.

74 Ẹ kiyesi i, agbo ni. Ti ẹ ba ni iṣẹju kan si i, mo fẹ lati ṣalaye eleyi. Ẹ mọ, ni alẹ ijelo, mo fi i silẹ. N ko tilẹ ṣalaye rẹ fun ijọ mi paapaa. Ẹ ranti igbati O fidi majẹmu naa mulẹ, ti O fidi majẹmu naa mulẹ fun-un? O mu abo ewurẹ kan, o mu ẹgbọrọ maaluu kan (abo ọmọ maaluu), o pin wọn si meji, o si mu agbo pẹlu. Ẹ ranti, nigbati iru-ọmọ alade igbagbọ rẹ, ẹ ranti wipe kii ṣe abo; akọ ni. Akọ ni - a mu ileri naa ṣẹ. Ẹ kiyesi i, agbo kan - akọ. Akọ, lati ba Ọrọ naa mu. Oun ni Ọrọ naa - agbo yẹn. Kii ṣe abo - a kọkọ fi wọn rubọ, ṣe ẹ ranti, ni Gẹnẹsisi 15. Eyi abo - ni o kọkọ ṣaaju. Lẹyinnaa, o mu agbo. Agbo ni o kẹyin. Akọ, agbo, Ọrọ naa ti a pese; kii ṣe abo ewurẹ, ijọ ẹlẹkọ-adamọ, ijọ kan. Kii ṣe abo, ijọ; ṣugbọn akọ, agbo naa. Amin!

Idi niyẹn ti a fi bi I ni oṣu kẹrin;

75 kii ṣe oṣu kejila. Ijọ Roomu ni o fi si (ọjọ-ibi oriṣa oorun), wọn da a pọ mọ tirẹ ni ọjọ kẹẹdọgbọn Oṣu Kejila, nigbati wọn maa n ṣe ere idaraya. Ti o ba mu … wo itan ijọ, iwọ yoo mọ wipe wọn kan da iyẹn silẹ ni lati ṣe … ọjọ-ibi oriṣa oorun ni (oorun), nigbati o dabi ẹni wipe o duro soju kan. Ko yipada fun ọjọ marun-un, lati ogunjọ Oṣu Kejila titi di ọjọ kẹẹdọgbọn.

Wọn pa ọjọ-ibi Ọmọ Ọlọrun ati oriṣa oorun pọ, wọn da ẹsin Kristẹni pọ mọ oriṣa. Wọn sọ Oṣu Kejila di … A ko lee bi i ni Oṣu Kejila, ni ọjọ kẹẹdọgbọn. Kini idi, yinyin maa n pọ ni Judea. A bi i gẹgẹbi a ṣe n bi awọn aguntan: a bi i ni akoko ibẹrẹ òjò. A si nilati bi i labẹ ami agbo, nitori agbo ni Oun iṣe. Oṣu Kẹrin si ni a maa n bi agbo. Bẹẹni. A bi i labẹ ami agbo. Ohun ti O jẹ niyẹn: Oun ni agbo Ọlọrun. Oun ni o gba ipo Isaaki nibẹyẹn!

Amin! Ṣe ko ye yin ni?

76 Oun niyẹn, a fihan gbangba wipe a ki yoo pe iru-ọmọ alade naa nipa abo - ijọ, ẹbọ abo-ewurẹ ijọ ẹlẹkọ-adamọ; rara, ṣugbọn nipa Oun, Ọrọ agbo naa ti o farahan, nitori Oun ni Ọrọ naa, ati agbo naa. O ni a ko pe e ni orukọ abo; ṣugbọn nipa orukọ akọ. Oun yoo mu awọn eniyan kan lati inu awọn Keferi, kii ṣe fun orukọ abo, ṣugbọn fun orukọ akọ - wọn yoo maa jẹ orukọ Rẹ̀. Akiika! Ki lo n ba yin lẹru nipa rẹ nigbanaa? Keferi yoo maa jẹ orukọ Rẹ̀, agbo naa; kii ṣe orukọ abo, ijọ. Kii ṣe abo, ṣugbọn Akọ. Halleluyah!

77 Iru-ọmọ alade naa yoo ri i. Ṣe ẹ ko ri i wipe Malaki ori kẹrin ti o n wa si imuṣẹ ni, ni dida pada sinu Ojulowo igbagbọ, ani Ọrọ Ọlọrun? Dajudaju, ẹyin eniyan lee ri iyẹn. A ko nilo lati ṣalaye rẹ ju bayi lọ. Ẹ fi ijọ ẹlẹkọ-adamọ yẹn silẹ, ẹyin eniyan. Ẹ pada sinu Ọrọ yẹn. Ohùn ikẹyin ọjọ, ati ami ikẹyin ọjọ, ni yoo da awọn eniyan pada si Ojulowo igbagbọ naa. Malaki ori kẹrin sọ bẹẹ: ẹ pada si Ọrọ naa,

78 Oun si ni Ọrọ naa. Kii ṣe abo; Akọ ni. Amin. Orukọ Jesu Oluwa.

Ọrọ naa ti a fihan, nipa ileri: Ọrọ ti o ṣe ileri Johanu Mimọ 14:12, "…iṣẹ ti mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu"; Malaki 4, nkan kannaa ni O sọ nibẹyẹn; Luuku 17 naa sọ fun wa wipe ni ikẹyin ọjọ, ifarahan aye yoo wa bi o ṣe ri ni igba aye Sodomu, Ọlọrun yoo sọkalẹ wa, yoo si farahan ninu ara eniyan, yoo si mọ aṣiiri ọkan. Jesu wipe nkan yẹn yoo ṣẹlẹ ni ọjọ ti a ba n fi Ọmọ eniyan han ni ikẹyin aye.

Ṣe ẹ ri i, kii ṣe ijọ, "Darapọ mọ eleyi, darapọ mọ iyẹn"; ṣugbọn wa si ọdọ Rẹ ni! Ohun ti awọn ti Abrahamu … iru-ọmọ Abrahamu fi ṣe irubọ wọn niyẹn. Dipo iru-ọmọ rẹ nipa ti ara, iru-ọmọ rẹ nipa ti ẹmi nkọ? O si gbe iru-ọmọ alade naa, iru-ọmọ ayaba. Amin! Ah, iba ṣe wipe ẹ lee ri i ni. Ẹ ranti, kini o jẹ? Ara ati ẹmi n sọkan papọ ni, wọn n di ẹyọkan.

79 Ẹ wo o. Ni Matteu ori kẹta, Ọmọ Ọlọrun niyi, ti a bi ninu ẹran-ara nipasẹ wundia, O jade lati inu ilu wa, O jade tọ Johanu Onitẹbọmi lọ. Oun niyẹn, o duro sinu omi. Bibeli wipe Ọrọ Oluwa maa n tọ awọn wolii wá. Ṣe bẹẹ ni? Wolii si ni Johanu. Wọn ko ni wolii fun ọpọlọpọ ọdun, ṣugbọn oun niyi, wolii ni, o duro sibẹ. O si n sọtẹlẹ wipe Jesu yoo wá. O ti wa ninu aginju, o sọ wipe oun ri ami kan. Ọlọrun sọ fun-un wipe ami yẹn yoo maa tẹle Messiah naa nigbati O ba de.

O ni, "O wa ni aarin yin nibikan bayi. Ẹnikan wa ni aarin yin, bata ẹniti emi ko to gbe. A o fihan lọjọ kan. Nigbati a ba si fihan, nigbanaa ni emi yoo maa dinku si i; Oun yoo si maa pọ si i." O wo, o si ri ami naa. O ni, "O ti de bayi. Wo o, Ọdọ-aguntan Ọlọrun ti o ko ẹṣẹ aye lọ."

80 Oniwaasu ijọ Onitẹbọmi atijọ nni, Ọmọwe Davis, ẹniti o baptiisi mi sinu idapọ ijọ Onitẹbọmi, n ba mi sọrọ lori iyẹn ni igba kan. O ni, "Njẹ o mọ ohun ti o ṣẹlẹ nibẹyẹn, Billy?"

Mo ni, "Rara, n ko mọ ọ, Ọmọwe."

O ni, "Ohun ti o ṣẹlẹ niyi. A ko baptiisi Johanu ri." O ni, "Johanu baptiisi Jesu, lẹyinnaa, Jesu naa baptiisi Johanu."

Mo ni, "Emi ko mọ nipa iyẹn." Nitorinaa, mo bẹrẹ si gbadura nipa rẹ. Ninu iran ni oru ọjọ kan, mo ri ohun ti o ṣẹlẹ. Ko fi igba kankan … Ko fi igba kankan … Jesu ko fi igba kankan baptiisi Johanu. Ṣugbọn ẹ kiyesi i. O ni, "Iwọ ni o yẹ ki o baptiisi mi, eeṣe ti O fi tọ mi wa?"

Jesu ni, "Fi silẹ bẹẹ."

81 Ẹ wo oju awọn mejeeji, awọn ọkunrin meji ti o ṣe pataki julọ lori ilẹ aye. Ọlọrun niyẹn; wolii Rẹ si niyi. Ọrọ naa si n tọ wolii wa. Ti Ọrọ naa ba wa ninu ara, yoo tọ wolii lọ. Ibi yoowu ti o wa, yoo tọ wolii lọ. O nilati ṣe bẹẹ. Bibeli sọ bẹẹ. Rara. Oun ni o de yii … Oun ni Ọrọ naa. "Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa … Ọrọ naa si di ara, o si n ba wa gbe."

Ọrọ naa tọ wolii wá, ninu odò, lati ṣe imuṣẹ ati ifihan asọtẹlẹ Rẹ̀. Amin. Oun ni o duro yii. Oju awọn mejeeji pade ara wọn: ọkan jẹ wolii, ekeji si jẹ Ọrọ. Johanu rẹ ara rẹ silẹ niwaju Rẹ, o ni, "Iwọ ni o yẹ ki o baptiisi mi, eeṣe ti O fi tọ mi wa?"

O ni, "Fi silẹ bẹẹ, nitori bẹẹ ni o yẹ fun wa [o yẹ fun wa, o yẹ], lati mu gbogbo ododo ṣẹ." Johanu, ti o jẹ wolii, ti o si mọ Ọrọ yẹn, nitori Ọrọ naa tọ ọ wa, o mọ wipe ẹbọ naa niyẹn. Ni ibamu pẹlu ofin, a nilati fọ ẹbọ naa ki a to fi i rubọ. Bi o ṣe ri gan-an niyẹn. O baptiisi Jesu nitori Oun ni ẹbọ ti o n bọ. Ki o to bẹrẹ iṣẹ Rẹ ni gbangba, a nilati kọkọ baptiisi rẹ, nitori a nilati fọ ẹbọ naa ki a to fi i rubọ. Amin! O baptiisi Rẹ. Nigbati o ṣe bẹẹ, lọgan, O jade kuro ninu omi, o wo oke, o si ri Ẹmi Ọlọrun bii adaba; ohùn kan si ti inu rẹ jade, o ni, "Eyiiyi ni ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu Mi dun si lati maa gbe inu Rẹ." Ọlọrun ati eniyan di ọkan.

82 Adamu ati Eefa jẹ ọkan ni atetekọṣe, nigbati O ya wọn si ọtọọtọ, o ṣubu, nitori Ọrọ naa. O padanu Ọrọ

naa. O ṣubu. Bẹẹ ni gbogbo igba ijọ kọọkan ṣe ṣubu bẹyẹn, nitori ṣíṣì Ọrọ naa tumọ, wọn n fi aaye gba olutumọ ti o… Satani tumọ rẹ fun Eefa. "Ah, dajudaju, iyẹn ko lee ri bẹẹ… Dajudaju, gbogbo nkan wọnyi ko lee ri bẹẹ… Eyi ko lee… Ah, bẹẹni, mo mọ. Dajudaju…"

Ṣugbọn ti Ọlọrun ba ti sọ bẹẹ, bẹẹ ni o ri niyẹn, ko si "dajudaju" kankan nipa rẹ mọ. A nilati tun ọ bi! O nilati gba Ẹmi Mimọ! Yala iyẹn, tabi ki o ṣegbe.

Ẹ kiyesi Oun,

83 Oun niyi, Jesu ati Ọlọrun di ọkan. Wọn di ọkan. Gẹgẹbi o ṣe ri ni Eedẹni … Adamu ati Eefa jẹ ẹmi kannaa ni atetekọṣe. A pe orukọ wọn ni Adamu, ṣe ẹ ri i. O jẹ Adamu ati Eefa papọ. Nigbati … a ya wọn sọtọ fun idanwo, kini o ṣẹlẹ? Eefa ṣubu nipa Ọrọ naa - Ọrọ naa niyẹn. Adamu wa a lọ lati ra a pada, ṣugbọn ko lee ṣe e. Ko yẹ lati ra a pada. Lẹyin eyi ni Adamu keji de lati ra ijọ pada, eyiti iṣe ojiji, apẹẹrẹ.

84 Gẹgẹbi Adamu ati Eefa ṣe nilati jẹ ẹmi kannaa, Kristi ati ijọ nilati jẹ Ẹmi kannaa, iṣẹ-iriju kannaa - "iṣẹ ti mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu." Ṣe ohun ti mo n sọ ye yin? Wọn nilati parapọ di ọkan. Ẹran-ara ati ẹjẹ ati Ọlọrun nilati pade lati jẹ Ẹmi kannaa. Jesu Kristi ati ijọ Rẹ jẹ Ẹmi kan.

Bawo ni ijọ ṣe lee ṣẹ́ iṣẹda? Bawo ni ijọ ṣe lee ṣẹ́ ohun ti Kristi ni ki wọn ṣe? Bawo ni a ṣe lee ṣẹ́ ẹ, ki a si tun sọ wipe a jẹ ti Kristi? "Bi ẹyin ba n gbe inu mi, ti ọrọ mi si n gbe inu yin, ẹ beere ohun ti ẹ fẹ, a o si ṣe e fun yin. Emi ni ajara, ẹyin si ni ẹka." Iye ti o wa ninu ajara ni o n lọ sinu ẹka lati so eso - oluso eso - gbogbo ẹka ti ko ba so eso rere ni a o ge kuro.

Bi awọn ijọ ti a ti ọwọ eniyan gbe kalẹ ti ṣe niyẹn: wọn yoo tu u ka, wọn yoo da Ọrọ naa ru, wọn yoo si bẹrẹ lati ibẹ. Ti ọkan ba ti bẹrẹ, ọkan yoo lọ bayi, ọkan yoo lọ bẹyẹn. Ki ẹ to mọ ohun ti o n ṣẹlẹ, awọn ọmọ ita diẹ yoo ti wọle wa, wọn yoo si mu ero ti ara wọn wa. Ki ẹ to mọ ohun ti o n ṣẹlẹ, wọn yoo di Babiloni nla kan. Oun yoo si ge e kuro. Ko si igba ti ijọ ẹlẹkọ-adamọ ṣubu ti o tun pada dide mọ. Gbogbo wọn ni o ṣubu, wọn ko si pada wa mọ. Yoo mu ọkunrin kan lati ibomiran, yoo si mu u jade wa. Dajudaju.

85 Ẹ kiyesi eyi bayi. Wọn nilati di ọkannaa. Jesu sọ nigbanaa wipe iye ti o wa ninu Oun ni yoo wa ninu ijọ Oun. Ohun ti O si ṣe ileri fun ikẹyin ọjọ niyi: wipe iye ti o wa ninu Kristi, ti o wa ninu … yoo farahan ni ọjọ ti aye ba wa ni ipo Sodomu, gẹgẹbi o ti ri nisisiyi. Ṣe ẹ ko ri i ni, arakunrin, arabinrin? Iwulo wo ni didarapọ mọ ijọ jẹ, ti o ko ba ni Kristi ninu aye rẹ, ki Kristi si maa fi ara Rẹ han ninu aye rẹ? Bi o ṣe ri niyẹn. "Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o ba gbagbọ lọ." Oun ni o sọ bẹẹ. Bawo ni o ṣe lee sọ wipe … ti ko ba ri bẹẹ, bawo ni o ṣe lee sọ wipe o jẹ ti Kristi?

O sọ pe, "Arakunrin Branham, bawo ni o ṣe ro wipe o lee mu ki iyẹn ba awọn eniyan lara mu ni ọjọ ọlaju nla yii, nigbati ohun gbogbo jẹ ijọ ẹlẹkọ-adamọ?"

86 Mo beere lọwọ obinrin kan laipe yii, wipe, "Ṣe Kristẹni ni ọ?" - ni ile-iwosan kan. O ni, "Mo fẹ ki o ye ọ wipe mo maa n tan abẹla kọọkan ni alaalẹ." Bi ẹni wipe iyẹn ni nkankan ṣe pẹlu jijẹ Kristẹni!

Mo lọ gbadura fun obinrin miiran, obinrin kan si wa nibẹ ti ara rẹ ko da, oun ati ọmọkunrin rẹ. Mo ni … mo wọle. Mo ni, "Arabinrin, ṣe iwọ yoo … bẹẹni, mo mọ ẹniti o jẹ. Iwọ ni Iyaafin Oliver."

O ni, "Bẹẹni, Arakunrin Branham." O ni, "Mo ti ṣaisan pupọ, Arakunrin Branham. Dokita ko ri ohun ti o n ṣe mi. Ṣe iwọ yoo gbadura? Idi ti mo fi pe ọ niyẹn."

Mo ni, "Eeṣe, dajudaju, Arabinrin Oliver." Mo ni, "Ṣe iwọ yoo tẹ ori rẹ ba?..."

O ni, "Duro na. Fa aṣọ iboju yẹn!"

Mo ni, "O dara, ko buru." Mo ni, "Mo kan fẹ gbadura ni. Ṣe Kristẹni ni iwọ?"

O ni, "Ijọ Eleto ni awa."

Mo ni, "O dara, kii ṣe ohun ti mo beere lọwọ rẹ niyẹn. Mo beere wipe ṣe Kristẹni ni ọ."

O ni, "Fa aṣọ iboju yẹn!" Ṣe ẹ ri i? Bi o ṣe ri niyẹn… Bawo ni ẹnikan ṣe lee jẹ… Okunkun biribiri niyẹn, iyatọ ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti o n ja wọn kuro ninu ibukun Ọlọrun. Iyẹn wa ninu gbogbo ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Bẹẹ ni. Arakunrin, maṣe lọ si ọdọ abo; Oun ni ki o gba. Maṣe gba orukọ abo; ti akọ ni ki o gba. Orukọ Rẹ ni ki o gba.

87 O sọ pe, "Arakunrin Branham, bawo ni o ṣe lee mu ki o ba awọn eniyan lara mu loni? Bawo ni iwọ yoo ti ṣe e?"

O ṣe ileri wipe Oun yoo ṣe e. O ni, "Ma bẹru, agbo kekere. Ifẹ inu rere Baba yin ni lati fun yin ni ijọba naa." Bawo ni yoo ti ṣe e? Oun ṣì jẹ Jehofa-jire sibẹ. O ṣì jẹ Jehofa-jire sibẹ: Ọlọrun lee pese ijọ kan fun ara

Rẹ. O lee gbe ọmọ dide fun Abrahamu lati inu awọn okuta wọnyi! Dajudaju - Oun ni Jehofa-jire.

O sọ pe, “Ṣe yoo ṣiṣẹ?” Yoo … dajudaju. Ọlọrun ṣe ileri rẹ. “Ṣe o ro wipe o lee ṣe e?” Emi ko lee ṣe e, ṣugbọn Oun yoo ṣe e. Kii ṣe ojuṣe temi lati mu ki O ṣe e; ojuṣe temi ni lati waasu rẹ. Iṣẹ Tirẹ ni lati fidi rẹ mulẹ - iyẹn wa lọwọ Rẹ. Ti mo ba duro ti otitọ, Oun yoo duro ti i. O ti fidi rẹ mulẹ, yoo si ṣe e. O sọ pe, “Okunkun ṣu biribiri.” Bẹẹni, mo mọ wipe okunkun ṣu biribiri, ati wipe gbogbo awọn oniwaasu wọnyi n lọ sibi ẹgbẹ ipaniyan nla yii. O ni, “Kini iwọ yoo ṣe nipa iyẹn?”

88 Iyẹn ran mi leti itan kekere kan. Mo fẹ sọ eyi ki a to danu duro.

Ni Calrsbad, New Mexico, wọn ni koto kan nibẹ, nibiti iwọ yoo ti wọ inu ilẹ lọ fun maili kan, sinu ibẹyẹn … Emi ko fẹran nkan yẹn ri. Nṣe ni wọn dabi eku ninu iho ilẹ. O si wọ isalẹ ilẹ lọ. Ibẹ maa n dudu bii ọganjọ oru ni. Ọmọdẹbinrin kan wa nibẹ, bii ọmọ kekere ti o wa nibẹyẹn. Ẹgbọn rẹ ọkunrin naa duro si ẹgbẹ kan, pẹlu ẹ̀ṣọ́ ti o n mu wọn lọ si isalẹ.

Wọn wa nibi okunkun yii, nibẹ… Imọlẹ wa nibẹ ni igba yẹn. Wọn tan gbogbo ina silẹ. Ọkunrin yii, fun … ẹṣọ naa kọja sibi imọlẹ naa. Ọmọdekunrin yii n rin pẹlu rẹ, o n wo ẹṣọ naa. Nitorinaa, ẹṣọ yii bọ si ẹgbẹ kan, o si mu ohun ti a fi n tan ina, o pa ina naa. Kai! Okunkun biribiri bo ilẹ; wọn ti wọ isalẹ ilẹ lọ fun maili kan, ṣe ẹ mọ, o ṣokunkun de ibi wipe o ko lee ju ọwọ rẹ, o ko lee ri ohunkohun.

89 Ọmọdẹbinrin yii bẹrẹ si fi gbogbo agbara rẹ kigbe. O n fo soke-sodo, o n kigbe kikankikan… Bi o ṣe n kigbe lọwọ, ọmọkunrin kekere yẹn, ti o wa ni ẹgbẹ kan, sọ pe, “Ah, aburo mi obinrin! Ah, aburo mi obinrin!”

O ni, “Kini o n fẹ, ẹgbọn mi ọkunrin?”

O ni, “Maṣe bẹru. Ọkunrin kan wa nibi yii ti o lee tan awọn ina naa.”

Ọkunrin kan wa nibi yii ti o lee tan ina: Oun ni Jehofa-jire. Ọkunrin kan wa ni aarin wa ni aṣalẹ yii: Ẹmi Mimọ ni. O lee tan ina. Oun ni Ọrọ naa - ọkunrin kan ti o lee tan ina wa nibi yii. Emi ko mọ bi yoo ti ṣe e. Kii ṣe fun mi lati mọ. Ṣugbọn O mọ bi yoo ṣe tan ina na. Oun ni o ṣe ileri naa.

O ṣe e nibẹyẹn… Nigbati Abrahamu gbe ọbẹ soke lati pa ọmọ rẹ, o tan ina. O tun lee tan ina naa ni aṣalẹ yii.

90 Ẹ jẹ ki a tẹriba fun iṣẹju kan.

Ọlọrun, ṣe iranwọ, ki Ó lee tan ina kekere ti o wa ninu ọkan rẹ yẹn. Ẹyin ọrẹ, ẹ ti ri Ẹmi Mimọ nla naa ni aarin wa ni ọsẹ yii. Ko si iyemeji nipa iyẹn. Ṣugbọn, jẹ ki a tan imọlẹ kekere yẹn ni aṣalẹ yii. Maṣe padanu rẹ, arakunrin mi, arabinrin mi. Mo ro wipe ori kan nipa Abrahamu nibi yii ti fihan - bi a ṣe n so o papọ siwa ati ṣẹyin lati Gẹnẹsisi de Ifihan - o ti fi wakati ti a n gbe inu rẹ han. Wọn tun ti kọ Kristi ni orilẹ-ede wa. Ilẹ-riri ni oniruuru ibi, Sodomu ati Gomora, ijọ wa ni ipo rẹ, o n di aworan ẹranko naa: gbogbo nkan wọnyi ti ṣẹlẹ gẹgẹbi Bibeli ti sọ. Ẹyin eniyan si mọ bẹẹ.

Laisi iriri nla yii pẹlu Kristi… Ti iye Kristi ba wọ inu rẹ…

91 Wo ara rẹ ninu diigi Ọlọrun, ki o wo o boya o lee da ara rẹ mọ ni aṣalẹ yii.

Ti o ba wa ni igba aye Noah, ni akoko ẹkun omi, iha wo ni iwọ iba fi ara mọ? Ti o ba wa ni igba Mose, iha wo ni iwọ iba wa? Ti o ba wa ni igba aye Kristi, nigbati gbogbo ijọ lodi si Oun… O nilati da nikan duro ninu awọn ohun ti O ṣe. Kiki wipe Ọlọrun wa pẹlu Rẹ - iyẹn ni koko. O fẹrẹ jẹ wipe gbogbo awọn ọmọ-ẹyin Rẹ ni o lọ kuro lọdọ Rẹ. Ṣugbọn iha wo, ni ipo ti o wa bayi, nibo ni iwọ … iha wo ni iwọ iba wa? Iha wo ni iwọ yoo wa bayi, nigbati o tun ri i laarin wa?

O wa nihin. O lee tan imọlẹ si ọkan rẹ, ki O si fi Ẹmi Mimọ kun aye rẹ. Ẹni melo ni o wa nibi yii, pẹlu bi ẹ ṣe tẹ ori ati ọkan yin ba, ẹni melo ni yoo gbadura pẹlu mi fun iṣẹju melo kan?

92 Baba wa ọrun, a mọ wipe Iwọ kii wa lati ṣe nkan, lati lee fihan wipe O lee ṣe e. O n ṣe e fun idi kan ni. Oluwa, ni ọsẹ yii, a dari mi lati duro de iṣẹju yii, titi di akoko yii, wipe lakọkọ, ki wọn lee ri i wipe a fidi Ọrọ naa mulẹ. O kọja iyemeji bayi. Ẹnikan yii, Abrahamu, ni a so gbogbo awọn eniyan ti o wa ninu Bibeli mọ, a si ri ibi ti a wa bayi.

Baba, pẹlu ọrọ kekere yii (ṣugbọn iwọnba ti mo lee ṣe niyẹn), mo gbadura bayi wipe Ẹmi Mimọ nla ti o wa nihin yii, ti o mọ aṣiiri gbogbo ọkan, yoo ba ọkan yẹn sọrọ bayi. Ṣe bẹẹ, Oluwa. Ba ọkan naa sọrọ, eyiti ki yoo lọ ti O ba de ni aṣalẹ yii. Ti ilẹkun ba ti ni aṣalẹ yii, ti wọn yoo ba ku ni ọna si ile wọn, tabi ti ọkọ ba gba wọn, ti wọn si ku, tabi ti wọn ku, ti a si ri oku wọn ni ori ibusun wọn ni owurọ, a ki yoo gba wọn la. Ọlọrun o, jọwọ maṣe jẹ ki ẹnikẹni ninu wọn lọ bẹyẹn.

Bi o ba ṣe wipe wọn kan darapọ mọ ijọ lasan ni, Oluwa, maṣe jẹ ki oju ti wọn lati jade, ki wọn si beere lọwọ Ọlọrun fun ifikunni Ẹmi Rẹ, ki iye Rẹ lee wọ inu wọn. Ti awọn nkan wọnyi ko ba tii ye wọn, bẹẹ ni ko ṣe ye awọn ọmọ-ẹyin pẹlu; ṣugbọn wọn duro titi di igba ti a tu Ẹmi Mimọ jade. Nigbanaa ni o to ye wọn, wọn si kọ Bibeli. Mo gbadura, Baba, nisisiyi, wipe ki O ba ọkan kọọkan sọrọ, si jẹ ki wọn mọ wipe ọkunrin naa ti o lee tan imọlẹ ti wa nibi ilẹkun ọkan wọn bayi.

93 Bi a ṣe tẹriba, ẹni melo nihin yii ni yoo jẹ olootọ, ti yoo wipe, "Arakunrin Branham, mo mọ wipe ọna mi ko tọ niwaju Ọlọrun." Mo fẹ ki o na ọwọ rẹ soke. Ki gbogbo eniyan tẹriba, ṣugbọn na ọwọ rẹ soke. "Ọna mi ko tọ pẹlu Ọlọrun." Ki Ọlọrun bukun fun ọ. Ki Ọlọrun bukun fun ọ. Bẹẹni. "Mo…" Ọwọ… "Mo mọ wipe ọna mi ko tọ pẹlu Ọlọrun." Ṣe ẹ ri i, ohun ti mo n gbiyanju lati ṣe ni wipe: ki a ri ojurere lọdọ Ọlọrun fun isin iwosan nla ọla. Ti mo ba lee ri ojurere, emi ko gbagbọ wipe ẹnikẹni yoo ṣẹku bikoṣe … Ọlọrun yoo wosan, ti mo ba ṣaa lee mu ki awọn eniyan gbagbọ.

94 Iwọ ti o ko ni baptisiimu Ẹmi Mimọ… O si mọ wipe ororo naa niyẹn. Ti o ko ba ni ororo ninu fitila rẹ, o ko lee wọle. Njẹ ẹ gbọ ọ ri ninu awọn iwe-iroyin wipe awọn ijọ Alagba, ijọ Luther - ẹ wo iwe-iroyin atigba-de-igba ti awọn Ọkunrin Kristẹni Oniṣowo - awọn ijọ Luther, Alagba, ati Katoliiki paapaa, ọgọọgọrun wọn n gbiyanju lati wa baptisiimu Ẹmi Mimọ. Emi ko mọ boya awọn ọkunrin oniṣowo ti o gba ẹkunrẹrẹ ihinrere gbọ yẹn loye wipe wọn ki yoo ri i gba.

95 Bibeli wipe nigbati wọn de, wọn ni, "Ẹ fun wa lara ororo yin." Wọn ni … awọn wundia ti o sun… Wọn mọ wipe awọn ni gbogbo akoko yẹn lati ni ororo, ṣugbọn wọn ko ṣe e. Nigbati ọkọ iyawo ti fẹrẹ de, wọn ni, "Ẹ fun wa lara ororo yin."

Wọn ni, "Iwọnba ti o to fun wa ni a ni. Ẹ lo ra lọdọ awọn ti n ta." Nigbati wọn lọ, ọkọ iyawo de, iyawo si wọle lọ. A sọ wọn sinu okunkun biribiri, nigbati wọn ji, wọn ri i wipe igbasoke ti ṣẹlẹ, a si fi wọn silẹ, nibiti ẹkun oun ikerora (igba ipọnju) ati ipayinkeke yoo gbe wa.

Arakunrin ati arabinrin mi ni aṣalẹ yii, ọrẹ mi, ti o ko ba tii ni Ẹmi Mimọ, ṣugbọn ti o ni idaniloju wipe o nilati ni i, ṣe iwọ yoo na ọwọ rẹ soke, ki o wipe, "Gbadura fun mi, Arakunrin Branham. Mo gbagbọ wipe iwaju Ọlọrun ni a wa. Gbadura fun mi. Emi ko ni Ẹmi Mimọ." Ki Ọlọrun bukun fun ọ. Ẹ wo awọn ọwọ nibigbogbo. Ṣe o fẹ ẹ nigbanaa?

96 Bayi, mo mọ - fun ẹyin ijọ Eleto, ati Onitẹbọmi, ati bẹẹ bẹẹ lọ - ọpọlọpọ gbawere-mẹsin ni o maa n tẹle iṣẹ-iranṣẹ iwaasu yoowu. Si ẹyin ijọ Luther - mo n ka itan Martin Luther, ọkan ninu awọn iwe ti a kọ nipa rẹ nibi laipẹ yii. Wọn ni ko jẹ iyanu wipe Martin Luther tako ijọ Katoliiki, o si mu u jẹ, ṣugbọn lati duro gidi laarin gbawere-mẹsin ti o tẹle isọji rẹ. Iyẹn si jẹ… Gbogbo isọji ni o maa n ni adalupọ ero. Ẹ mọ bẹẹ. Ṣugbọn ẹ ranti bayi, iyẹn kan fihan wipe Ojulowo wa ni.

Nigbati ẹ ba ri alupayida owo dọla, ti ẹnikan n ṣe bi ẹni wipe oun ni nkankan, ẹ ranti wipe Ojulowo kan wà, lara eyiti wọn ti ṣe alupayida yẹn. Ti ko ba ri bẹẹ, a jẹ wipe iyẹn ni Ojulowo, ṣe o ye yin. Nitorinaa, ẹ mọ wipe iyẹn ko lee jẹ Ojulowo. Ojulowo nilati wa.

97 Ojulowo naa ni Jesu Kristi, ẹniti o wa nibi, ti o mọ gbogbo aṣiiri ọkan rẹ nisisiyi.

Mo fẹ beere lọwọ rẹ, ti o ba ti ri i, ti o si ti gbọ awọn ẹri wọnyi, nipa oniruuru awọn ti a ti wosan, ati bi a ti sọ aṣiiri ọkan awọn eniyan di mimọ ni ọsẹ yii, o si… Oun ni o n ba ọ sọrọ yẹn. Oun niyẹn. Emi ko mọ boya o gbagbọ wipe ti mo ba gbadura fun ọ, yoo ran ọ lọwọ? Ranti, a fi Ẹmi Mimọ funni nipa gbigbe ọwọ le ni. Peteru - lẹyin ti Filipi lọ si Samaria, ti o si baptiisi awọn eniyan nibẹ ni orukọ Jesu Kristi - sibẹ, Peteru wá, o si gbe ọwọ le awọn eniyan, Ẹmi Mimọ si ba le wọn, ṣe ẹ ri i.

Ti o ba gba iyẹn gbọ, n ko mọ boya iwọ yoo goke wa sihin yii - ẹnikọọkan ti a koi tii gbala, tabi ti koi tii ni Ẹmi Mimọ - ṣe iwọ yoo wa sihin, ki o si duro sibi yii fun iṣẹju kan, ki o jẹ ki n gbadura fun ọ. Ti ẹ ba lee wa lati aarin awọn ijoko, tabi ibikibi yoowu ti o ba wa, ṣaa duro sihin yii. Goke wa sihin yii ki n gbadura pẹlu rẹ fun iṣẹju kan. Ki Ọlọrun bukun fun yin.

98 Gbogbo yin ẹ maa kọ orin "A Fẹrẹ Yi Mi Lọkan Pada," ti ẹ ba fẹ, Arabinrin Downing, ti o ba fẹ. O dara. Ṣe ẹ ki yoo maa bọ bayi, ẹyin ara. Ki Ọlọrun bukun fun ọ, arakunrin mi. Ki gbogbo eniyan dakẹ jẹẹ bayi, ẹ maa gbadura. Eyi lee jẹ akoko ti o ṣe pataki pupọ. O lee jẹ oun ni iyatọ laarin iku ati iye fun ọpọlọpọ eniyan. Ṣe gbogbo yin wa nihin ni ọsẹ yii? Ṣe ẹ ti ri Ẹmi Mimọ, ohun ti O ṣe ni ọsẹ yii laarin awọn eniyan?

…………… lati gba Kristi;

Tọka si ọkan kan bayi lati………

Ṣe o ki yoo ha wa bi, iwọ ti o ko ni Ọlọrun, ti o ko ni Ẹmi Mimọ? O lee wipe, "Ọmọ ijọ ni mi, Arakunrin

Branham.” Ohun ti … ohun ti mo n sọ kọ niyẹn. Ohun ti mo n sọ ni wipe, ṣe o kun fun Ẹmi Ọlọrun? O ko lee ri ọjọ miiran ti o dara ju isisiyi lọ, nigbati a fi Jesu Kristi han laarin wa. Ti o ba ku ki ilẹ to mọ nkọ, ti o ko si lee pè? O ki yoo ha wa bayi, nigbati Ó n pè? Bẹẹ ni, ẹ ṣaa maa bọ, ẹ maa bọ.

…………… gbogbo eniyan wa loni;

“A fẹrẹ yi mi lọkan pada,” Maṣe pẹyinda…

O ki yoo ha wa bayi bi? Mo mọ … nkankan n sọ fun mi ninu ọkan mi wipe ẹnikan wa ti o n fa ṣẹyin. Ma ṣe bẹẹ, arakunrin, ma ṣe bẹẹ.

…, awọn angẹli wa nitosi;

Adura n ti ọkan ọwọn jade;

Iwọ alarinkiri, maa bọ.

99 Ẹ feti silẹ, ẹyin ọrẹ, ṣe ẹ gbagbọ wipe ni ọsẹ yii, Ẹmi Mimọ ti fidi rẹ mulẹ wipe Oun n sọrọ nibi yii? Ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin. O yẹ ki o pọ ju bayi lọ. Mo ni imọlara yẹn. Ṣe ẹ ri i, Oun ki iṣe … nkankan ṣọwọ odi sibẹ. O sàn ki o wá. Ranti, emi ko lee … emi ko lee fi ipa mu ọ wa lodi si ifẹ tirẹ, ṣugbọn mo gbagbọ wipe eyi lee jẹ akoko fun ohun gbogbo ti o ti n foju sọna fun, o lee jẹ wipe o ti fẹ ṣẹlẹ bayi.

Eyi si lee jẹ (mo lero wipe ko ri bẹẹ), o lee jẹ igba ti o kẹyin ti a o pe ọ. Ranti, ki yoo maa ba ọ ja nigbagbogbo. Yoo pè; lẹyinnaa, yoo kuro lọdọ rẹ, ko si ni wa mọ laelae. O ko ṣe wa bayi? Ṣe o ko ni goke wa sibi yii, ki o si fi ara rẹ han niwaju Ọlọrun? Sọ pe, “Emi yoo wa duro. Emi yoo rin ọna naa. Oju ko ti mi. Mo jẹ ọmọ ijọ. Ṣugbọn mo fẹ ki gbogbo aye mọ wipe mo ṣetan lati gba Kristi sinu ọkan mi, ani Ẹmi Mimọ. Mo n bọ wa bayi lati ṣe e. Mo ṣetan lati ṣe atunṣe - ki n jẹ Kristẹni tootọ, obinrin rere, ọkunrin gidi.” O ki yoo ha wa bi? A o duro.

Maa bọ wa, bẹẹni. Lati iwaju ita ati laarin awọn ijoko, ẹ maa bọ. O kan … mu iduro rẹ.

100 Ọrẹ, mo lee ma ri ọ mọ laelae ni aye yii. Ṣugbọn ti n ko ba ri ọ, ranti, emi ki yoo ni idalẹbi. Bẹẹ ni Kristi naa. O ti fi ara Rẹ han pẹlu rẹ. Iwọ yoo ri i ti yoo ṣe nkan kannaa laipẹ yii. O dara. Maa bọ bayi, mu iduro rẹ. O wipe, “Eeṣe, Arakunrin Branham, o n ṣe idajọ.”

Rara, emi ko ṣe idajọ. Imọlara ti mo ni yii ni mo n ṣe idajọ rẹ̀. Nkankan wa nihin ti o wipe, “Ah, wọn sì ṣẹku. Ọpọlọpọ ni o ṣẹku,” ṣe ẹ ri i. Ni bayi, o lee wipe, “Ko buru, mo ti darapọ mọ ijọ, Arakunrin Branham. Ọmọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni mi.”

Emi ko … iyẹn kọ ni mo n sọ, ọrẹ. Iyẹn kọ ni mo n beere rara. Ohun ti mo n beere ni pe, “Ṣe o ti ni iye Kristi?”

O ni, “Arakunrin Branham, mo ti fedefọ.” Iyẹn dara, ṣugbọn kii ṣe ohun ti mo n sọ niyẹn. O ni, “Arakunrin Branham, emi ko hu iwa ibi si ẹnikẹni ri.” Kii ṣe ohun ti mo n sọ niyẹn. Ṣe iye Kristi wa ninu rẹ? Maṣe dẹ́jàá, ọrẹ. Ma ṣe e, ma ṣe e, ma ṣe e, ma ṣe bẹẹ. Yoo jẹ … nigbati iku ba de ba ọ, yoo ti pẹ ju nigbanaa. Ma ṣe e. Jọwọ ma ṣe e.

101 A ni ọpọlọpọ nibi nisisiyi, mo fẹ fi aaye silẹ fun awọn diẹ si i. Emi yoo gbadura fun awọn wọnyi, lẹyinnaa … ki a lee wọle lọ, ki a wọ inu iyara lọ nibẹyẹn, ki a lee wa gbe ọwọ le wọn, ki wọn lee gba Ẹmi Mimọ. Lẹyinnaa … a o gbadura bayi fun awọn wọnyi. Ẹ tẹriba fun iṣẹju kan.

Baba wa ọrun, awọn ti o tẹriba niyi. Ọkunrin ati obinrin ni wọn - awọn ti n lọ si ainipẹkun ni wọn. Wọn gbọdọ lọ, a mọ iyẹn. A ri awọn ilẹ-riri, ati aye ni ipo ti o wa bayi, a si ri i ti Kristi tọ wa wa, ti O si n ṣe awọn nkan ti O n ṣe. A ri i wipe iṣẹ-iranṣẹ iwaasu naa, ani Ọrọ naa, n jade lọ. A si ri i ti Oun naa wa, ti O si ti Ọrọ naa lẹyin wipe otitọ ni - nipa mimọ aṣiiri gbogbo ọkan. Awọn eniyan wọnyi ti jade sita lati mu iduro wọn. Wọn ko lee ṣe eyi fun ara wọn. Wọn wa nitoriti a dari wọn lati wa ni.

102 Njẹ Baba, mo n gbadura fun wọn nibi yii, kii ṣe wipe ki a lee gba wọn la nikan, ṣugbọn ki a lee fi Ẹmi Mimọ kun wọn. Gba bẹẹ, Oluwa.

Jẹ ki olukuluku ẹniti o duro sibi yii kun fun Ẹmi, jẹ ki isọji bẹrẹ lati ibi yii lọ kaakiri orilẹ-ede yii, eyiti yoo mi agbegbe yii ati orilẹ-ede yii yika. Gba bẹẹ, Oluwa. Ki gbogbo ijọ - ninu ijọ Eleto, Onitẹbọmi, Alagba, Church of Christ, ijọ Luther, tabi ohun yoowu ti o lee jẹ - jẹ ki isọji ṣẹlẹ, Oluwa, nipasẹ awọn eniyan wọnyi, bi wọn ṣe n pada lọ pẹlu Ẹmi Mimọ tootọ, ki wọn maa fi Ọlọrun han ninu igbe-aye wọn. Gba bẹẹ, Baba. Tirẹ ni wọn bayi, mo si fi wọn fun Ọ. A o mu wọn wọle bayi, a o si gbe ọwọ le wọn, Oluwa, ki wọn lee gba Ẹmi Mimọ. Ni orukọ Jesu.

Bi gbogbo wa ṣe tẹriba,

103 mo fẹ ki awọn eniyan wọnyi tẹle ọkunrin ti o wa ni ọwọ ọtun yin yii, ki emi lee … ki a lee wa si ọdọ yin, ninu iyara nibẹyẹn. A ni ibikan fun yin nibi yii, nibiti ẹ ti lee kunlẹ. A o wa gbe ọwọ lee yin, ki ẹ lee gba Ẹmi Mimọ. Ti aisan ba n ṣe ọ, o … ki a lee mu ọ lara da, tabi ohunkohun ti o ba nilo. Ẹ lọ sibi bayi, ki a lee wọle pẹlu yin. Awọn miiran n bọ si i, ṣugbọn … diẹ … ko si aaye fun wọn lati naro. A o fi eyi ṣe ipe meji. Ẹ wọle lọ si ẹgbẹ ibi yii. O dara. Ki Ọlọrun bukun fun yin.

104 Si ẹyin ti ẹ wa nibi yii, bi wọn ṣe n jade lọ, ẹyin naa ko ṣe goke wa sibi yii fun adura. A o tun kun ibi yii bayi. A n wọle lọ sibẹyẹn lati gba baptisiimu Ẹmi Mimọ. A n wọle lọ, lẹyin ti a ti ri idanimọ Jesu Oluwa niwaju wa ni ọsẹ yii, ti a si mọ laisi iyemeji kankan, wipe Oun ni o wa nihin yii. Ẹ ranti, Ẹmi Mimọ kannaa, Jesu kannaa ti o lee sọ fun mi, ohun ti o n ṣe awọn eniyan wọnyẹn: ibi ti wọn wà, ẹniti wọn jẹ́, ibi ti wọn ti wá, ohun ti yoo ṣẹlẹ si wọn; ẹ si mọ wipe ko kuna lẹẹkan ri, ko si lee kuna laelae, ko lee kuna laelae - Ẹmi Mimọ yẹn kannaa ni o sọ fun mi wipe ki n ṣe eyi. Bẹẹ ni. Mo n ṣe e nipa idari Ẹmi Mimọ.

105 Bi a ti n ṣe eyi … kete ti awọn ẹgbẹ yii ba ti jade kuro ninu iyara keji, ki a to lọ si ibẹ, a fẹ ki ẹ wa. Ẹyin ti ẹ wa nihin yii, ẹ maa bọ. Ẹ goke wa sibi yii. Ẹyin ti o ku sibi yii ti ẹ n fẹ baptisiimu Ẹmi Mimọ, ṣe ẹ ki yoo wa nisisiyi? Ẹ goke wa sibi yii. Ki Ọlọrun bukun fun ọ, ọdọmọkunrin yii.

Ti aisan ba n ṣe awọn kan, ti wọn ko si kun fun Ẹmi Mimọ, ẹ ko ṣe wa gba Kristi? Ẹ gba a, nigbanaa ẹ o ni anfaani ti o dara si i… Aisan ṣẹṣẹ kọlu obinrin yii ni … ko lee … o da a loju bi ẹni wipe ko lee farada a. Wọn n ran-an lọwọ lati lọ sinu iyara naa. Ẹ maa bọ bayi, ẹyin ti o n kan, aaye pupọ wa fun yin lati naro bayi.

Ẹ maa bọ, ẹyin ti ẹ jẹ ọmọ ijọ - Eleto, Onitẹbọmi. A ko sọ wipe ki ẹ…

106 Ẹ feti silẹ, ẹyin ọrẹ. Mo mọ pe wọn maa n sọ pe, “Pẹntikọsti - wọn fi ọgbọn ori ko Pẹntikọsti jọ.” Irọ niyẹn. Iriri ni Pẹntikọsti. Awọn ijọ Eleto n gba a, ijọ Onitẹbọmi n gba a, gbogbo wọn n gba a. A ko fi ọgbọn ori ko Pẹntikọsti jọ; iriri ni. Ti o ko ba tii ni iriri Pẹntikọsti yẹn, wa gba a nisisiyi.

Ẹ ranti, ti ẹ ba gba mi gbọ wipe mo jẹ iranṣẹ Rẹ̀, wolii Rẹ̀, ẹ ranti, Ojulowo baptisiimu Ẹmi Mimọ tootọ wà. Laarin gbogbo gbawere-mẹsin ti o n ṣẹlẹ, Ojulowo Ẹmi Mimọ wa - Ojulowo ti Ọlọrun. Ẹ wa gba a gbọ nisisiyi.

107 Ẹ ki yoo ha wa bi, bi a o ṣe kọ ẹsẹ kan tabi meji ninu orin yii, ki o lee da mi loju wipe ọkan mi mọ. Nigbati mo ba fi ilu yii silẹ, ẹjẹ ki yoo si lori…

Mo mọ wipe O n ba awọn ẹlomiran sọrọ. Ẹ ko ṣe wá? Ki Ọlọrun bukun fun ọ, iwọ ọmọdekunrin yii. Ki Ọlọrun bukun fun gbogbo yin, ẹyin ti ẹ naro yika. Bẹẹ ni. Ẹ maa bọ, lati ibikibi ninu ile yii - ni ita, ninu ile, ni iwaju, nibikibi - ẹ maa bọ wa bayi, si isalẹ nibi. Ẹ mu iduro yin fun Kristi. Ẹ maṣe tiju Rẹ.

Ti o ba n ku lọ… Njẹ ti ọkan rẹ ba n fò bayi nkọ? Si ranti o, ẹniti o n ba ọ sọrọ yẹn, ọwọ Rẹ ni ọkan rẹ wa. O mọ aṣiiri ọkan rẹ. Mo sọ ọ ni orukọ Oluwa. Ọpọlọpọ ni o wa nibi yii ti o yẹ ki o wá. Ẹ ko ha ṣe wa? O sọ pe, “Ṣe emi ni, Arakunrin Branham?” Bẹẹni, iwọ ni. Ti ko ba da ọ loju, maṣe dẹ́jàá.

………………………… ọwọn;

Alarinkiri, maa bọ.

“A fẹrẹ yi mi lọkan pada,” ikore…

Bẹẹ ni, ikore ti fẹ kọja. Maa bọ. Yoo ti pẹ ju lọjọ kan. Maṣe duro de wakati miiran, iṣẹju miiran, dide, ki o si maa bọ. Iwọ ọdọmọkunrin, mu afẹsọna rẹ dani. Iwọ ọdọmọbinrin, mu ọkọ afẹsọna rẹ dani. Iya, mu Baba dani. Ẹ maa bọ bayi, gbogbo eniyan - ọdọmọbinrin, ọdọmọkunrin, ẹni yoowu ti o jẹ, baba arugbo, iya arugbo - ẹ maa bọ. Oun niyi. Ti o ba jẹ… Ẹ ranti ohun ti mo ṣẹṣẹ fihan yin ninu Bibeli. A o pa ọ lara da, ti o ba lee gba iru-ọmọ Abrahamu.

……… ni lati kuna!

Ẹkun kikoro ti o bani ninu jẹ:

“A fẹrẹ, ṣugbọn - o sọnu.”

Ẹ jẹ ki a tẹriba bayi.

108 Jesu Oluwa, Ọlọrun o, wa gbogbo ọkan ri. Ṣe iwadi gbogbo wa, iwọ Ẹmi Mimọ nla. Ọlọrun o, maṣe jẹ ki eyi jasi asan … fun ẹnikẹni. Jẹ ki ẹnikọọkan, ẹnikọọkan, Oluwa, ri igbala. Maṣe jẹ ki ẹnikẹni ninu wọn ṣako lọ, Oluwa. Mo gba wọn ni orukọ Jesu Oluwa gẹgẹbi iyun lara ade Oluwa mi, ifarahan ẹniti n bẹ nihin nisisiyi -

ọwọn-ina nla naa ti o n lọ kaakiri inu ile yii, ti o n lọ sinu gbogbo ọkan. Mo gbadura, Ọlọrun, wipe ọkan yẹn yoo ja kuro ninu ide, yoo si dide, yoo fi tayọtayọ wa sọdọ Jesu Kristi. Sọ pe, “Oluwa, gbogbo ohun ti mo jẹ, emi niyi. Mu mi, mọ mi, Oluwa, ninu ile amọkoko nla Rẹ, kun mi, ki O si ṣe mi ni ọmọkunrin tabi ọmọbinrin Ọlọrun.” Gba bẹẹ, Oluwa.

Jẹ ki eyi ri bẹẹ,

109 bi a ṣe n tẹsiwaju lati kọ ẹsẹ orin kan si i, ṣe ẹ o ṣe bẹẹ? A o danu duro bayi, ni kiakia, nitori a nilati lọ ba awọn ti o wa nibi yii.

“A fẹrẹ yi mi lọkan pada,”………

Ẹ maa bọ, ẹ maa bọ bayi, ẹ ki yoo ha wa bi? Ki Ọlọrun bukun fun ọ, ọmọ. Ni ẹnu ọmọ-ọwọ ni O ti n gba iyin.

Ah, “A fẹrẹ yi mi lọkan pada,”

Maṣe lọ;

Jesu…………………

Oun ni o n pe ọ yẹn, O n ba ọkan rẹ sọrọ. “N ko mọ boya emi ni?” Ti iyemeji kekere kan ba wa, maa bọ.

…………… wọn n duro si itosi,

Adura n ti ọkan ọwọn jade wa;

Iwọ alarinkiri, maa bọ.

110 Ẹ jẹ ki a tẹriba bayi, nigbati awọn wọnyi n mura silẹ. Bi ẹ ṣe duro sihin yii, ẹ wo isalẹ. Ẹ ranti wipe ẹ nilati wa nipa ohun kan ti o wa ninu yin, ti o n sọ fun yin wipe nkankan kuna ninu aye yin. Mo fẹran iduro yin. Ẹ ranti, Jesu wipe, “Ti ẹ ba tiju mi niwaju eniyan, emi naa yoo tiju yin niwaju Baba mi ati awọn angẹli mimọ. Ṣugbọn ẹniti o ba jẹwọ mi niwaju awọn eniyan, oun ni emi yoo jẹwọ rẹ niwaju Baba mi ati awọn angẹli mimọ.”

Awọn eniyan diẹ ni o wa lẹyin ibẹyẹn, ti wọn ṣetan lati darapọ mọ wa ninu adura, wipe ki a lee gba yin la, ki a si kun yin fun Ẹmi Mimọ. Ẹ sọ fun-un wipe ẹ kẹdun fun ohun ti ẹ ti ṣe, ẹ o si jẹ Kristẹni lati isisiyi lọ nipa oore-ọfẹ Rẹ, ati wipe ẹ fẹ baptisiimu Ẹmi Mimọ, eyiti yoo dari yin ninu gbogbo irin-ajo aye yii.

111 Baba wa ọrun, iyun ni wọn jẹ lara ade rẹ. Wọn ko lee wa … wọn ko lee wa bikoṣepe nkankan kilọ fun wọn. O si wipe, “Ko si ẹniti o lee wa bikoṣepe Baba mi ba fa a, gbogbo awọn ti Baba ti fi fun mi ni yoo wa.” Wọn ti wa bayi, nitori nkankan sọ fun wọn wipe ki wọn wa. A jẹ wipe O ti bẹrẹ iṣẹ kan niyẹn, Oluwa. Mo gbadura wipe ki O pari rẹ ni aṣalẹ yii ninu wọn, Oluwa, nipa sisọ wọn di ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun. Gba bẹẹ. Ki ẹnikẹni ninu wọn maṣe sọnu. Mo fi wọn fun Ọ gẹgẹbi ẹbun Ọrọ Rẹ ati ifarahan Rẹ. Ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

112 Ẹ maa lọ sinu iyara naa titi ti a o fi wa si ọdọ yin. Ẹ maa lọ sibẹ. Awọn adena yoo dari yin lọ sibẹ. Ni bayi, n ko mọ boya awọn oṣiṣẹ ijọ yoo wá. Ẹ tele awọn wọnyi wọle lọ, ẹyin oṣiṣẹ lati awọn ijọ miiran. Ẹyin iranṣẹ Ọlọrun, ti o fẹ tẹle wa lọ si ibẹyẹn, lati mọ boya a ṣe eleyi ni ọna ti o tọ tabi bẹẹkọ, ẹ maa bọ pẹlu wa. Ẹ wa kunlẹ pẹlu awọn eniyan yin, wipe ki wọn lee gba Ẹmi Mimọ. Ki ẹnikọọkan maa bọ… Ẹyin iranṣẹ Ọlọrun, ẹnikẹni ninu yin. Eleto, Onitẹbọmi, Alagba, ẹni yoowu ti o jẹ, ẹ maa bọ. A pe yin. Ẹ maa bọ pẹlu awọn eniyan wọnyi.

113 Ẹyin oṣiṣẹ ninu ijọ lorişirişi ti o mọ bi a ṣe n gbadura pẹlu awọn eniyan, ati bi a ti n gbe ọwọ le wọn, ẹ maa bọ bayi. A fi awọn wọnyi si ọwọ yin. Ẹbun Ọrọ naa ni wọn jẹ. Ẹ ki yoo ha wa ni akoko yii, ẹyin oṣiṣẹ inu ijọ, ki ẹ si lee pada ki a to yi ipade yii pada laarin iṣẹju kan? Ẹ maa bọ bayi. Ẹ wọle. Iyẹn dara. Ẹ wọ inu iyara naa lọ - iyara pọ ni ẹyin ibẹyẹn. Ẹ wọle lọ, ki ẹ ṣe ohun gbogbo ti ẹ ba lee ṣe lati ran awọn eniyan iyebiye wọnyi lọwọ.

Jesu Oluwa ni o mu wọn wa. O ti mu wọn ninu àwọ̀n ihinrere. Ẹyin ẹ mu wọn lọ si ibẹyẹn, ki ẹ si jẹ ki a gbadura pẹlu wọn, wipe ki Ọlọrun fi Ẹmi Mimọ kun ẹnikọọkan wọn. Ẹ ti awọn ilẹkun, ẹ duro si ibẹyẹn, titi ti yoo fi ṣẹlẹ. O ṣe ileri wipe Oun yoo ṣe e. O ṣe ileri, yoo si mu ileri Rẹ ṣẹ. O jẹ olootọ si ileri Rẹ gẹgẹbi O ṣe jẹ olootọ lati farahan niwaju wa nibi yii. Oluwa, bukun fun wọn.

114 Ẹyin iranṣẹ Ọlọrun, ṣe ẹ wa nibi? Ẹyin oniwaasu, ẹyin ọmọ ijọ ti o ni ifẹ si i ti ẹ si n wo, ẹ n mu ki awọn eniyan gba Ẹmi Mimọ. Iṣẹ yin niyẹn bayi, ẹ tẹle wọn lọ. Ẹ duro ti awọn eniyan yin. Ẹyin ọkunrin ti a ti kọ

daradara, ti ẹ ni iriri pẹlu Ẹmi Mimọ, ẹyin obinrin ti a ti kọ daradara, ti ẹ mọ ohun ti o tumọ si, ẹ lọ sọdọ awọn arabinrin nibiti wọn wa lẹyin ibẹyẹn. Ẹyin ti ẹ mọ ohun ti o yẹ ki ẹ ṣe, ẹ duro ti wọn lẹyin ibẹyẹn. Akoko niyi fun yin. Asiko iṣẹ yin niyi. Akoko niyi lati fi awọ yin han, lati lọ. Ki Ọlọrun bukun fun yin. Bẹẹ ni. Ẹ duro si aaye yin, ki ẹ si wọle lọ pẹlu wọn. Ẹ duro sibẹ, ki ẹ si ri i daju wipe a ṣe e, a si ṣe e ni ọna ti o tọ. Ẹ duro sibẹ titi ti ẹ o fi ri adun Kristi ninu ẹnikọọkan wọn. Ọlọrun yoo bu ọla fun yin nitori iyẹn. Amin ati amin!

Ah, mo fẹran iyẹn. Ẹ wo awọn ti o lọ si ẹyin nibẹyẹn.

115 Njẹ ẹnikan wa nibi ti ko wọle, ti o si yẹ ki o wọle? Ti o ba wà, ṣe iwọ yoo dide, ki o si tẹle awọn oṣiṣẹ inu ijọ wọnyi wọle? Ṣe bẹẹ, ṣe o gbọ? Ti ẹnikan ba wa nibi yii ti ko ro wipe oun wa nibiti o yẹ ki oun wa…

Ẹ ranti, arakunrin, arabinrin, emi ko lee mu ki nkan yii ṣẹlẹ, ṣe o ye yin. Ọlọrun ni o n ṣe awọn nkan wọnyi; kii ṣe emi. Mo gbadura wipe ki Ọlọrun gba nkan wọnyi fun yin, ki O si fun yin ni iriri baptisiimu Ẹmi Mimọ. Gbogbo ẹyin ti ẹ fẹran Jesu Oluwa, ti ẹ si fẹ wọ ile lọ gbadura, ẹ lọ si ẹyin ibẹyẹn bayi, ki ẹ si gbadura pẹlu awọn eniyan wọnyi, ṣe ẹ o ṣe bẹẹ? Ẹ ṣeun. Ẹ ṣeun pupọ.

116 Njẹ ẹ mọ, nigbati mo ba ri awọn oṣiṣẹ inu ijọ ti wọn n tẹle awọn eniyan, mo ti … mo fẹ sọ eyi nipa ẹyin eniyan nibi yii. Iyẹn fi ohun ti ẹ jẹ han. Mo ti lọ kaakiri, ati laarin awọn eniyan ti o yẹ ki o kun fun Ẹmi, mo si ri i bi wọn ti n pe awọn eniyan sibi pẹpẹ. Ẹ ko si lee ri i ki awọn eniyan wọle lati gbadura pẹlu wọn. Iyẹn fihan wipe Ikabọdu ti ṣẹlẹ. Ẹmi Oluwa ti lọ kuro, ṣe ẹ ri i. Ṣugbọn nigbati ẹ ba ri itara yẹn, ati ina, ati ifẹ - ifẹ fun ọkan eniyan…

Ẹ kiyesi i wipe ni gbogbo ọsẹ yii, mo farabalẹ, mo si n kiyesi imọ-ẹmi-yatọ ati iru awọn nkan bẹyẹn, wipe awọn eniyan yoo ri i, ki wọn si ri i wipe Ẹmi Mimọ wa nitosi - lẹyinnaa, emi yoo pe ipe sibi pẹpẹ. Ohun ti mo n ṣe ye ẹyin oniwaasu, ṣe ẹ ri i - lati pe ipe sibi pẹpẹ nigbati wọn ti ni idaniloju. Ọgọọgọrun wọn ni o wa nibẹyẹn bayi lati gba Ẹmi Mimọ. Ọpọlọpọ ni o wọle lọ lati gbadura pẹlu wọn.

Njẹ ti ẹlomiran ba wa nibi yii, ki a lee…

117 Emi yoo sọ eyi: wipe ẹ ti ri ifarahan Kristi ni ọsẹ yii, wipe O n fi ara Rẹ han nibi yii. Ẹ ti ri i. Ẹ ranti wipe ẹjẹ kankan ki yoo si lọrun mi ni ọjọ naa, bi o tilẹ jẹ ọla. Yoo ṣẹlẹ lọjọ kan. Ẹ ṣaa ranti, a o wà nibẹ. Ko si ẹni yoowu ti o jẹ, iwọ yoo wa nibẹ lọnakọna. “A ti fi lelẹ fun eniyan lati ku lẹẹkanṣoṣo, lẹyin eyi, idajọ.” Gbogbo wa ni yoo wa nibẹ.

Ti o ko ba ni idaniloju pipe wipe o ni Kristi, ani Ẹmi Mimọ ninu ọkan rẹ, ki O si maa fi ara Rẹ̀ han nibẹ ninu ifẹ, ati alaafia, ati ayọ, ati awọn eso Ẹmi, ki iye Kristi si maa gbe inu rẹ - njẹ ki o ranti, ẹjẹ rẹ ko si ni ọrun mi. Bẹẹni Oun naa ki yoo jẹbi, nitoriti O ti farahan niwaju rẹ, O si ti fi ara Rẹ han nibi yii, ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ. Ẹni melo ni yoo jẹri si iyẹn nipa nina ọwọ soke, ki ẹ si wipe, “Mo ti ri i ni ọsẹ yii.”? O dara. A jẹ wipe a ko ni ẹbi, a ko ni awawi. Njẹ ẹnikẹni wa ti o … ẹnikan si i ti o fẹ lati wá, ki n lee wipe, nigbati akoko mi ba to lati kuro ni ọla, bi Oluwa ba fẹ, ki n lee sọ wipe mo bọ lọwọ gbogbo ẹjẹ nibi isọji naa. Mo sa gbogbo ipa mi, Oluwa. Mo fi le Ọ lọwọ. Ni bayi, iwo ṣaa … ẹnikọọkan.

118 Ẹni melo ni o wa nibi yii ti o ṣaisan tabi ti o ṣe alaini, ti o si fẹ ki a gbadura fun ọ? Ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin loke. O dara - ninu gbogbo ile yii ni. Emi yoo fẹ ki ẹ ṣe nkankan fun mi. Ṣe onigbagbọ ni yin? Mo fẹ ki ẹ ṣe nkankan fun mi bayi. Ẹ gbe ọwọ yin le ara yin. Ẹ gbe ọwọ yin le ara yin. Ẹ wo o, mo fẹ ki ẹ gbadura - ẹ ṣaa gbadura.

Ẹ ranti. Gbogbo awọn eniyan ti o fẹ wa sibi ila adura ni ọla gbọdọ tete de ibi yii, ki wọn si gba kaadi adura. Ẹ mu u dani ni ọwọ yin nigbati akoko pipe ila adura ba to. Ti o ba ni olufẹ kan, ẹyin ọmọ ijọ Eleto, Onitẹbọmi, Alagba, tabi ẹnikẹni yoowu ti o jẹ, ti ẹ ba ni alaisan kan ti ẹ … Ẹ tẹle wọn wa. Ẹ tẹle wọn wa sori ila adura. Ẹ wa, ẹ gba kaadi adura. Ki ẹ mu kaadi adura naa wa sori ila. Awọn adena yoo gba a. Wọn yoo … ẹ wa, ki a gbadura fun yin. Mo gbagbọ wipe Ọlọrun yoo ṣe ohun nla ni ọla. Mo ni ireti wipe yoo ṣe e. Idi niyẹn ti mo fi n pe ipe sibi pẹpẹ, mo n ṣe ohun gbogbo ti mo lee ṣe lati ri ojurere pẹlu Rẹ.

119 Bi a ṣe tẹriba bayi, ti gbogbo yin si n gbadura fun ara yin… Bibeli wipe, “Ami wọnyi ni yoo ma ba awọn ti o ba gbagbọ lọ.” Iwọ gbadura fun ọkunrin tabi obinrin ti o gbe ọwọ rẹ le, nitori oun naa n gbadura fun ọ. Maṣe gbadura fun ara rẹ; gbadura fun wọn. Ẹ gbe ọwọ yin le ara yin ki ẹ si gbadura. Ẹ ṣaa gbe ọwọ yin le … bẹẹ ni. Ẹ gbadura bi ẹ ti maa n ṣe ninu ijọ yin. Wipe, “Jesu Oluwa, wo arabinrin yii san, wo arakunrin yii san, ẹni yoowu ti o jẹ. Aisan n ṣe wọn, Oluwa. Onigbagbọ ni mi. Emi yoo tẹle Ọrọ Rẹ, Ọrọ Rẹ si wipe, 'Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ. Bi wọn ba gbe ọwọ le alaisan, ara wọn yoo da.' Mo gbe ọwọ mi le alaisan - alaisan yii, arakunrin alaisan yii, arabinrin alaisan yii. Mo gbadura, Ọlọrun, wipe ki O fidi Ọrọ Rẹ mulẹ, ami naa yoo tẹle e, a o si mu wọn lara da.”

120 Jesu Oluwa, mo gbadura fun wọn, ati fun awọn aṣọ-ilewọ wọnyi, wipe ni orukọ Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun, wipe ki O mu olukuluku ẹniti n bẹ niwaju Ọlọrun lara da.

Satani, o ti padanu ogun naa. Wọn ti ri ifarahan Kristi. Wọn ti gbọ Ọrọ Rẹ̀, wọn ti ri i ti o farahan. Awọn ẹlẹṣẹ wa ni ibẹyẹn, wọn n wa igbala. O ti padanu ogun naa. Jade kuro ninu awọn eniyan wọnyi, ni orukọ Jesu Kristi. Fi wọn silẹ, ki o maṣe da wọn loro mọ, ki Ọlọrun ọrun gbe wọn dide sinu iye lẹẹkan si i, pẹlu ilera ati okun. Ki awọn ti wọn ni kaadi adura maṣe nilo lati wa sori ila adura ni ọla. Jẹ ki Ẹmi Mimọ kọja laarin awọn eniyan wọnyi, ki O si mu olukuluku wọn lara da fun ogo Ọlọrun. (Ni bayi, tẹsiwaju, arakunrin.) Amin.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7